# Eeṣe Ti O Jẹ Bẹthlẹhẹmu Kekere?

Tucson, Arizona, USA

Ọjọ Kẹrinla, Oṣu Kejila, Ọdun 1963

1 Ohun ti a wà nihin ni owurọ yi fun niyi, gbigbe ife wa soke, "Kun un, Oluwa." Akoko kanṣoṣo ti a lee ni anfaani lati beere fun eyi niyi. Akoko kan yoo de ti a o wa ni odikeji, nigbana ni a ko ni ni anfani lati beere ohun kan. Nitorina, nisisiyi ti a ni anfaani lati beere, ti a si wa ninu irori pipe, emi ro pe ọkan ninu ohun ti o mu òye lọwọ ti ẹnikẹni lee ṣe nigbati Ọlọrun ti fun wa ni anfani lati lee ṣe bẹẹ, eyi ni lati lee ṣe e, ki a mu agogo wa kun nisisiyi pẹlu ifẹ ati aanu Rẹ.

2 Ẹnikan pejọ pẹlu wa nigba pipẹ sẹyin, nigba diẹ sẹyin, o si ti kọja lọ bayi. Eyi si jẹ ibanujẹ nla ninu ọkan wa fun Arakunrin Williams. Arakunrin Williams, ẹnitiṣe aarẹ ẹka ẹgbẹ wa nihin, baba rẹ papòdà. Ẹni ọdun melo ni baba rẹ, Arakunrin William? Ẹni ọdun mejidinlaadọrun. Eyi yoo jẹ nkan bi ọdun mejidinlogun ta-yọ akoko ti a ṣeleri fun eniyan lori ilẹ aye. Ẹni takun-takun. Nigba diẹ sẹyin, bi o ti n joko ninu ipade, mo sọ fun un, laiṣe aibọwọ fun Arakunrin William, mo wipe, "Iwọ ni irisi ọ̀dọ́ ju ọmọ rẹ lọ, Carl." Eyi n fihan pe a wa nihin loni, ni ọla, a ko si nibi mọ. A ko mọ igbati a o lọ, igbati yoo jẹ, ṣugbọn a mọ pe akoko naa mbọ. Mo n ro o, ṣugbọn iye ti a ni jẹ ohun nla, aye wa jẹ anfaani nla.

3 Àjálù nla kan ni a ni laipẹ yi, niti ẹnikan ti o ti n wa si ijọ wa fun igba pipẹ, lati ilu Chicago, o ku ni ọjọsi, nigbati o nlọ si ile, iya kan ni i ṣe. O ti fẹ ẹ pe ẹni aadọrin ọdun bi mo ti ro o, oun ati ọkọ rẹ ni wọn jọ nlọ ninu ọkọ wọn ni opopona ti o lọ si ilu Kansas, ni Missouri, nigbati iji nja lọwọ. Eniyan kan n wa ọkọ, ọkọ rẹ̀ sọ ijanu rẹ nu, o si kọlu ọkọ ti wọn, ọrùn arabinrin wa ṣẹ́ lẹsẹkẹsẹ. A ko si mọ igbati eyi mbọ wa ... Wọn pe lati fi to mi leti, bẹẹ ni emi pẹlu pe awọn ọmọ oloogbe naa nibigbogbo ti wọn wa ni orilẹ ede yi lati sọ fun wọn nipa iṣẹlẹ naa. Bi mo ti jẹ oluṣọ agutan wọn, emi ni o yẹ lati fi ọrọ naa to wọn leti. Bi mo ti n ro nipa bi o ti yẹki a lọ kiakia, mo si ni páálí suwiti kan ti arabinrin naa ṣe fun mi ni nkan bi ọsẹ kan sẹyin, ti o si fifun mi. Eyi n ṣe afihan bi eniyan ti lee kọja lọ kiakia lairo tẹlẹ. ... Ti o ba jẹ pe aye yi ni ireti wa pin si, awa yoo jẹ òtòṣi julọ. Jobu sọ ni ori kẹrinla Iwe rẹ pe, "Ah, Iwọ i ba fi mi pamọ ni ipo-oku, ki O si fi mi pamọ ni ikọkọ."

4 Njẹ o kiyesi bi ẹda ṣe ma n jẹri nipa Ọlọrun? A ri awọn igi, ewe wọn yoo rẹ̀ silẹ, iye igi naa yoo lọ sinu ilẹ, bii iboji, yoo duro sibẹ titi ibinu otutu yoo fi rekọja, yoo si pade wa pẹlu iye tuntun. Eyi si jẹ ẹri pe a o wa laaye pada. Oorun n yọ jade ni owurọ, bi ọmọ ọwọ, ko lagbara; lẹyin igba diẹ, yoo wa ni ile iwe, ile iwe giga; ni ọsan, yoo ni okun; ni ọsan yoo bẹrẹ si lọ si ibi wíwọ̀; ni aṣalẹ, yoo di alailagbara pada, yoo si ku. Ṣugbọn, eyi ki i ṣe opin oorun, yoo jade wa ni owurọ ọjọ keji lati jẹri si iran miiran, pe iye, iku; isinku, ati ajinde wà.

Ẹ̀dá paapa nibi-gbogbo n sọ nipa Rẹ. Bẹẹ ni ẹda jẹ ajẹri nla ni ọna miran, pe, a ko lee ni ajinde iye, bikoṣepe a wa laaye fun ifẹ Ọlọrun. Bayi, ti a ba gbin irugbin kan, ti irugbin naa si hu, yoo mu ewé-òdòdó tuntun jade. Ṣugbọn ti ko ba hu, ki yoo mu ewé-òdòdó tuntun jade wa, eyi yoo ri bẹẹ, ti irugbin naa ko ba mu ifẹ Ọlọrun ṣẹ. Sibẹ, ki i ṣe nitoripe o jẹ ododo ni o fi jinde, bikoṣe nitoripe o mu ifẹ Ọlọrun ṣẹ. A o jinde, ti a ba mu ifẹ Ọlọrun ṣẹ.

5 Emi gbagbọ pe Arakunrin Williams wa laaye fun ifẹ Ọlọrun, baba tootọ. Mo ri iyawo rẹ olufẹ, Iyafin Williams, to n joko sihin. Ọkọ tootọ, eyi si jẹ ọkan ninu awọn ifẹ Ọlọrun. Jijẹ baba pẹlu jẹ ọkan ninu awọn ifẹ Ọlọrun. A si sọ ọ di aaye si Ọlọrun nipaṣẹ Ẹmi Mimọ, eyi jẹ olori ifẹ Ọlọrun. Nitorina, lati sọ pe Arakunrin Williams ki yoo jinde, ki o si wa pẹlu wa lẹẹkansii, o tumọsi pe oje-igi ki yoo lọ sinu gbongbo ni akoko kan, ati pe ko si ajinde oorun. Ohun gbogbo n sọrọ nipa ajinde, fun un lati wa pẹlu wa lẹẹkansii, ohun gbogbo n jẹri si eyi. Lakọkọ, oorun, ododo, ẹda, iye eweko, ohun gbogbo sọ nipa rẹ. Ọrọ Ọlọrun si n sọrọ nipa rẹ. Atipe, lẹyin eyi, igbagbọ ti o wa ninu ọkan wa n ṣe afihan pe a o ri i lẹẹkansii. Ki Ọlọrun fi isimi fun ọkan rẹ. Ki a fi bu ọla kekere fun ẹniti o ti fi igba kan jẹ ara wa, ẹ jẹki a dide duro lori ẹsẹ wa, fun iseju kan.

6 Baba wa ọrun, a ko gbiyanju lati ni akojọpọ bi eyi ki a lee ri eniyan tabi ki a gbọ eniyan. A ti wá papọ lakoko kọọkan, fun ifidimulẹ Ọmọ Rẹ, Jesu Kristi, ati lati ṣe ijẹri fun awọn ti ko ni in, ki wọn o lee gba a. Ọkan wa n kẹ́dùn fun awọn ẹbi ti oloogbe fi silẹ, fun ìpapòdà arakunrin wa, ẹniti a ri laarin wa nigba diẹ sẹyin, o ti joko ni ọpọlọpọ igba ni ẹ̀ka yi kannaa. Ṣugbọn a gbagbọ pe Iwọ mu ki o gbe igbe aye rere, ti o kun fun iye lọnakọna, ọkan rẹ si wa pẹlu Rẹ loni, fun un ni isimi, Ọlọrun, titi di ọjọ naa ti a o ri i lẹẹkansii. Súre fun ọmọ rẹ̀ nihin, ati awọn ọmọ rẹ yooku, iyawo rẹ olufẹ, ati awọn eniyan ti o fẹran rẹ, eyi si jẹ gbogbo wa, Baba. Jẹki a fi ọkan wa si ipa ọgbọn niti eyi pe, awa pẹlu n di alailagbara atipe a gbọdọ lọ ni ọjọ kan, bẹẹni ki O ranwalọwọ lati pese ara wa silẹ fun wakati nla naa. Ti awọn kan ba si wa nihin ni owurọ yi, ti wọn ko ti i murasilẹ fun iṣẹlẹ kannaa, jẹki oni jẹ ọjọ ti wọn yoo sọ pe "bẹẹ ni" si Jesu Oluwa, ati ki a sọ wọn di aaye si i nipasẹ Ẹmi Mimọ. Nitoriti a beere ni orukọ Jesu. Amin. Ẹ joko.

7 Bayi, a fẹ ṣe awọn ifilọ diẹ. Mo sọ fun iyawo mi to n joko sinu apejọpọ ni owurọ yi pe, "Olufẹ, n o jade kuro ninu apejẹ owurọ …" A ni lati lọ si ìgboro lati ṣe awọn ohun kan. Mo si wipe, "N o jade ni agogo mẹwa owurọ ..." O wo mi. Mo wipe, "Ti nko ba jade ni agogo mẹwa, N o ra aṣọ tuntun mẹta ti o ba fẹ fun ọ." Nitorina, mo mọ ohun ti yoo ṣẹlẹ, mo ti jẹ gbese aṣọ mẹta, nitoripe, agogo mẹwa ti ku ogun iṣẹju bayi.

Ṣugbọn n o gbiyanju lati ṣe kiakia bi mo ba ti lee ṣe to.

8 Inu wa dun lati wa ni Jẹriko nihin pẹlu ẹyin ará ni owurọ yi, a si n pe yin lati wa ni aṣalẹ ọjọ Aje, si Jerusalẹmu, ni Tucson nibi apejẹ kan ti yoo waye nibẹ. Ṣe ẹ mọ pe ilu Phoenix wa ni afonifoji bi ti Jẹriko. Tucson, nibiti emi n gbe, wa ni ori oke, eyi ni Jerusalẹmu. Nibo ni iwọ wa, Tony? Eeṣe ti ẹnikan ko sọ pe "amin" ni ayika yi. Bayi, mo ti wa ninu takute kan, Tony ko tilẹ wa. Koburu, ni ọla, tabi ni aṣalẹ ọjọ Aje, ni a o ṣe apejẹ naa ni ilu Tucson, inu wa yoo si dun lootọ, ti ẹ ba lee wa si ibẹ, ki ẹ ya, ki ẹ si ri wa nibẹ. Akori ọrọ mi fun aṣalẹ ọjọ naa, bi Oluwa ba fẹ, yoo jẹ, "Awa Ti Ri Irawọ Rẹ ni Ila-oorun, awa si wa lati Foribalẹ Fun Un."

9 Ti o ba di ọjọ kọkandinlogun oṣu yi, tabi ti oṣu to mbọ, ọjọ kọkandinlogun Oṣu Kinni, n o bẹrẹ isọji kan nihin, ninu gbọngan yi, ni Gbọngan Ramada nihin, ni ọjọ kọkandinlogun, ogunjọ, ọjọ kọkanlelogun. Ti o ba di ọjọ kejilelogun, mo gbagbọ, a o bẹrẹ ... Ọjọ kẹtalelogun, mo ni aṣalẹ mẹrin lati lo nihin fun isọji. Ọpọlọpọ ẹyin Arakunrin ti i ṣe iranṣẹ Ọlọrun, inu wa dun lootọ lati ni yin ni owurọ yi, a fi tifẹtifẹ pe yin lati wa pẹlu awọn eniyan yin. Pataki julọ, awọn ti ẹ mọ ninu ilu yi, ti ko ti i mọ Jesu ni Olugbala. Lẹyinnaa, awọn ti wọn ṣe alailera ti wọn si mọ pe Ọlọrun n gbọ adura, a ni ilepa lati gbadura fun awọn alaisan ni akoko naa siwaju ipagọ nla ti yoo pa gbogbo ẹka papọ ni jake-jado orilẹ ede yi, eyiti yoo waye nihin, bẹrẹ lati ọjọ kejilelogun. Mo si ni igbẹkẹle pe inu yin dun lati gbọ eyi, nitoripe oniruru awọn oniwaasu ti o ta-yọ lo mbọ, mo si ni idaniloju pe ẹ o ni akoko nla.

10 Bayi, ni owurọ yi, mo ti ro nipa sisọrọ ni ẹka wa nihin, ninu eyiti ilu Phoenix ti jẹ ààyò ọkan mi. Mo maa n fẹran ilu Phoenix. Mo wa sihin, nigbati mo jẹ ọmọde ni agbegbe Wickenburg loke lọhun. Mo gbe ni adugbo Ikẹrindinlogun ati Henshaw. Adugbo naa jẹ aginju lakoko naa. Ṣugbọn mo ri i pe o ti di ilu, koburu, o ti wa ni aarin gbungbun ilu lootọ. Eyi n fihan pe akoko n yipada, igba n yipada. Ṣugbọn ohun kan wa ti mo fẹ sọrọ le lori ni owurọ yi, eyi ni Ẹni ti ko lee yipada, Ọlọrun, Ọlọrun ni, ninu eto Rẹ, Ọrọ Rẹ, ki i yipada. Akoko n yipada, awọn eniyan n yipada, ilana n yipada. Ṣugbọn Ọlọrun ki i yipada, O jẹ ọkan naa titi laelae.

11 Mo si ro o pe, bi a ti n bọ si akoko Keresimesi, ti a o ... boya n o sọrọ lori iwaasu Keresimesi kan. Ti ẹ ba ni Bibeli yin nihin, ti ẹ si fẹ ka a, nigbamiran awọn eniyan maa n ṣe bẹẹ lẹyin awọn ajihinrere ati awọn alejo ti a pe lati sọrọ, mo fẹ ka lati inu Iwe Ihinrere Matiu Mimọ, ori keji, fun ayọka Ọrọ naa.

NIGBATI a si bi Jesu ni Bẹthlẹhẹmu ti Judea, nigba aye Hẹrodu ọba, kiyesi i, awọn amoye kan ti ila-oorun wa si Jerusalẹmu

Wọn mbeere wipe, Nibo ni ẹniti a bi ti i ṣe ọba awọn Juu wa? Nitori awa ti ri irawọ Rẹ ni ila-oorun, awa si wa lati foribalẹ fun Un.

Nigbati Hẹrodu ọba si gbọ, ara rẹ ko lelẹ, ati gbogbo awọn ará Jerusalẹmu pẹlu rẹ;

Nigbati o si pe gbogbo awọn olori ati awọn akọwe awọn eniyan naa jọ, o bi wọn leere ibiti a o gbe bi Kristi.

... Wọn si wi fun Un pe, Ni Bẹthlẹhẹmu ti Judea ni nitori bẹẹ ni a kọwe rẹ lati ọwọ wolii ni wa.

Iwọ Bẹthlẹhẹmu ni ilẹ Judea, iwọ ko kere julọ ninu awọn ọmọ alade Juda, nitori inu rẹ ni Baalẹ kan yoo ti jade, ti yoo ṣe itọju Israẹli awọn eniyan mi.

12 Ki Oluwa fi ibukun Rẹ si kika Ọrọ Rẹ. Pẹlu awọn iwe ti mo kọ sihin, ati awọn Iwe Mimọ kan ti mo tọka si, n o fẹ ki ẹ fiyesi ọrọ mi fun igba diẹ, lori akori yi, Eeṣe Ti O Jẹ Bẹthlẹhẹmu Kekere.

Ṣe ẹ mọ, ni akoko Keresimesi, mo ro pe gbogbo wa, ọpọlọpọ wa, nko ni sọ pe gbogbo wa, ṣugbọn ọpọlọpọ wa ni a ti sọ iyebiye ohun ti Keresimesi jẹ nu. Bi mo ti kiyesi nihin, a ṣe awọn ọpẹ papa lọsọ; ni Ila Oorun, iru igi arẹwa kan tabi igi to n fi igba-gbogbo dara ni a maa nlo. Fun Ọpọlọpọ oṣu, tabi ọsẹ, boya fun oṣu kan tabi ọsẹ mẹfa siwaju ki Keresimesi to bẹrẹ, ọsọ ati ... Wọn ti sọ akoko Keresimesi di ti ọrọ-aje dipo ohun ti o tumọsi lootọ.

13 Emi ko gbagbọ pe a bi Kristi ni ọjọ kẹẹdọgbọn Oṣu kejila. Emi ko gba eyi gbọ rara. Awọn iṣẹlẹ ti o ṣẹlẹ lakoko ibi Jesu ko lee ṣẹlẹ ni akoko naa laelae. Awọn oke Judea maa n kun fun yinyin, yinyin maa n pọ pupọ ninu Oṣu kejila, ni ilẹ Judea. Ṣugbọn a loye eyi ninu ẹkọ itan, pe oṣeeṣe ki a bi Kristi ni igba iruwe, boya ni Oṣu kẹrin tabi Oṣu karun, iru akoko bẹẹ. Ṣugbọn nigbati wọn yi i pada, Oṣu yi ni wọn sọ ọ da, nigbati a sọ ẹsin Kristẹniti di ẹsin Romu, wọn sọ ọ di ọjọ ibi orisa-oorun, eyiti o wa ni oju oorun lati ọjọ kọkanlelogun titi di ọjọ kẹẹdọgbọn Oṣu Kejila, wíwọ̀ oorun ṣoro lati yipada botiwu-kori. Ọjọ ti wọn gbekalẹ yi wa fun ti ayẹyẹ ọjọ ibi orisa-oorun, wọn si sọ ọ di ti Ọmọ Ọlọrun.

14 Ṣugbọn, ẹ ranti eyi pe, iru ọjọ towu-ki o jẹ, a ko mu ọ̀wọ̀ ti o yẹki a fifun ọjọ ibi Jesu kuro. Bi o ti jẹ pe

Satani ti gba eyi lọwọ wa, o ti mu ki ipolongo Baba Keresimesi jalè gbogbo ijọsin ti o yẹki a maa ṣe. A si ti sọ ọ di ọjọ bii ti Ajinde, eyiti a fi ehoro tanilọ́rẹ ati pẹpẹyẹ pinki rọpo. Ki ni eyi ni lati ṣe pẹlu Ajinde? Ki ni iyẹn ni i ṣe pẹlu ajinde Kristi?

O dabi agbaye loni, awọn ọmọde ni oju popo lee sọ nipa fiimu Daikey Crockett ju bi wọn yoo ti sọ nipa Jesu Kristi. Wọn lee sọ fun yin si i nipa ofin kan, awọn ọdaran aye igbaani, ju bi wọn yoo ti sọ nipa Ọmọ Ọba Alade Iye ti a bi ni ẹgbaa ọdun din ọgọrun kan sẹyin. Ṣugbọn eyi ko mu ohun ti i ṣe ojulowo kuro lọwọ awa Kristẹni.

15 Ṣe ẹ rii, imọlẹ maa n tan julọ ninu okunkun. Mọnamọna ti o tan ni awọsanmọ ti o ṣu-dẹdẹ laṣalẹ n fihan pe imọlẹ lee wa ninu okunkun. Nigbati imọlẹ ba si n tan, eniyan ko lee ri ... ti oorun ba n ran, iwọ ko nilo imọlẹ eniyan pupọ. Ṣugbọn botiwu ki okunkun ṣu to, bi imọlẹ ba ti kere to, bẹẹ ni tìtàn rẹ yoo ti pọ to ninu okunkun. Bi okunkun ba ti ṣu to, bẹẹ ni imọlẹ yoo ti maa fi ara rẹ han daradara si i. Bi o ti yẹki awa Kristẹni maa ṣe ijẹri si ogo Ọlọrun, ti O ti fi Ọmọ Rẹ fun wa niyi. O yẹki akoko Keresimesi yi jẹ ohun ti o ta-yọ. O yẹki awa Kristẹni ... Botiwu-kori mu ki imọlẹ naa tan si i ni. Gbogbo aye ni a fi itannaa si loni. A ti ni Kristi, eyi si ni ohun ti o yẹki a gba laaye lati maa tan ni akoko okunkun ti a n gbe ninu rẹ yi.

16 A ro nipa bi Ọlọrun ti n ṣe nkan ni ọna ti ko wọpọ, nitoriti Oun funra Rẹ jẹ Ẹni ti ko wọpọ. Ọlọrun ko wọpọ. O jẹ Ẹniti o ta-yọ iṣẹda, Ẹni ailopin, si awa eniyan ti a lopin. Nitorina, ohun gbogbo ti O bạ se maa n ṣẹlẹ ni ọna ajeji. Ọlọrun si tobi to bẹẹ gẹẹ, ti O fi lo awọn ohun ti eniyan ko kà-sí ni aye lati ṣe afihan ara Rẹ.

A kiyesi i nihin, ninu akori ọrọ yi: Eeṣe Ti O jẹ Bẹthlẹhẹmu Kekere, ilu ti o kere julọ ni gbogbo Judea, ninu awọn ọmọ alade tabi ilu Judea, eeṣe ti Ọlọrun yan lati ran Ọmọ Rẹ lọ si ibẹ? Eyi ni ohun ti a fẹ sọrọ le lori. Bi Ọlọrun ti n mu ohun aye yi, mo gbagbọ pe Iwe Mimọ sọ pe, “Nipa iṣiwere ihinrere, Ọlọrun yan lati lo ohun ti aye ko kà-sí: Ohun ti awa pe ni titobi, ni Ọlọrun pe ni iṣiwere. Ohun ti a ka-si pupọ, ni Ọlọrun sọ pe ko dara. Ohun ti awa si pe ni ohun ti ko dara, ni Ọlọrun ṣe logo.

17 Mo n ro nipa igbati o ku diẹ ki a bi Jesu Oluwa, nigbati gbogbo awọn wolii, ati bẹẹbẹẹlọ, ti sọrọ nipa wiwa ẹniti yoo tun ọna Oluwa ṣe, bi a o ti sọ gbogbo oke di pẹtẹlẹ; ti a o si sọ afonifoji di giga, ti awọn oke yoo si fo bi agbo, ti awọn eweko yoo si patẹwọ. O si jẹ iranṣẹ Ọlọrun kan, wolii kan ti orukọ rẹ njẹ Johanu, ti o ti inu aginju wa, ko tilẹ ti ile ekọ Bibeli wa, irun-imu kun bo gbogbo oju rẹ, o si wọ awọ agutan laṣọ, ko wọ aṣọ alufa, o jade wa, lati kede pe, “Ijọba ọrun ku si dẹdẹ!” O si ṣoro fun awọn eniyan lati da iru irisi bẹẹ mọ, bi o ti mbọ laisi ami idanimọ lati inu ilana ẹgbẹ eniyan kan tabi ẹgbẹkẹgbẹ ti o darapọ mọ, Kaadi ile ijọsin kan tabi eyikeyi ijọ to n ti i lẹyin. Ohun iṣẹ iranṣẹ naa tobi pupọ, ọgbọn ori eniyan ko lee ṣe e, Ọlọrun kọ ọ ninu aginju. Iṣẹ iranṣẹ rẹ ko wa lati inu ẹkọ ile ẹko Bibeli kan. O n sọrọ nipa ejo ati aake ati awọn igi, ohun ti o mọ niyi, ẹda inu aginju, o n wo o bi o ti n siṣẹ. Ọna ti o si gba siṣẹ naa niyi. Ki i ṣe gẹgẹ bi alufa, ṣugbọn bi eniyan to n sọrọ nipa ẹda to n ri.

Ko rọrun fun awọn eniyan lati loye rẹ. Ko tilẹ ni aga iwaasu to n duro le, boya a kotilẹ gba a laye ninu eyikeyi ile ijọsin lati waasu, ṣugbọn o n ṣe iwaasu rẹ ni eti odo Jordani, boya o tilẹ n duro ninu ẹrọfọ ti o mu un de orunkun. Ṣugbọn awọn eniyan n jade wa lati gbọ iwaasu rẹ, awọn olotitọ ọkan. Wọn fẹ ẹ gbọ ọ nitoripe o jẹ ohun to yatọ, o jọ iwaasu otitọ.

Loni a ni lati maa sunmọ akoko ibi Kristi, iwaasu wa, o yẹki o maa ni ọrọ otitọ ninu, eyiti yoo mu ki awọn eniyan maa pongbẹ lati ri Jesu Kristi.

18 Ọlọrun mu eniyan yẹpẹrẹ yi, ẹniti ko ni imọ iwe, ko tilẹ lo ọjọ kan ri ni ile iwe, sibẹ Jesu sọ pe oun ni eyiti o gaju ninu awọn wolii ti aye ti i ni ri, nitoripe Ọlọrun n fihan ara Rẹ ninu ohun ti aye ko mọ.

Nigbati Jesu yan awọn ọmọ ẹyin Rẹ, bẹẹ naa lori. Ọpọlọpọ awọn eniyan ti o dara, ti wọn ni amuyẹ ti o dara lati ṣe iṣẹ naa ju awọn eyin lọ wa, awọn alufa wa, Jesu Kristi ko pe eyikeyi wọn. Awọn alufa wa ni ọjọ wọnni, awọn eniyan nla, awọn alufa, awọn ọmọwe, awọn olokiki, ṣugbọn Jesu Kristi ko pe wọn. O pe awọn apẹja, awọn agbowo-ode, ati bẹẹbẹẹlọ, lati ran iṣẹ Rẹ jade nipasẹ wọn. Bi O ti maa n ṣe nigba-gbogbo niyi.

19 Nigba aye Noah, Ọlọrun yan agbẹ, agbẹ lasan, lati ṣe ikede iparun aye igbanaa. Agbẹ yẹpẹrẹ, ki i ṣe alufa, agbẹ lasan. Nigba aye Noah, Ọlọrun lo ...

Nigba aye Mose, Ọlọrun lo ọmọ ẹru ti o sa kuro ni ilu, Oun ko lo alufa. Ọlọrun si jẹki oju gbogbo imọ ti o ti ni tẹlẹ nu titi o fi tẹ Ọlọrun lọrun, ni ẹyin aginju, o padanu imọ iwe rẹ, Ọlọrun si farahan si i ninu igbo to n jo, O si ran an lọ si ilẹ Egipti pẹlu ogbologbo ọpa ọwọ rẹ, lati ṣẹgun orilẹ ede ti o ni ...

Ṣe ẹ ri i, Ọlọrun maa nlo ohun yẹpẹrẹ lati fi ṣe afihan ara Rẹ. Ṣe ẹ ri i ... Ọrọ Rẹ nikan. Ọlọrun ṣe ẹda aye lati inu ohun ti ... Ohun ti ko si.

20 Ni ọjọ diẹ sẹhin, mo wa ni gbọngan Morris, fun ọkan ninu awọn ipade wa nla ti a ṣe ni ilu New York, mo

si n feti si ẹkọ kan ti onimọ-ijinlẹ Einstein gbekalẹ, ninu eyiti o ti n sọrọ lori awọn asopọ irawọ, ti o sọ pe yoo gba eniyan ni aadọjọ miliọnu ọdun lati de ibiti awọn irawọ naa wa, ti eniyan naa ba n sare bi imọlẹ, yoo si gbaa ni iye ọdun kannaa lati pada. Ti a ba ro o, aadọjọ miliọnu ọdun imọlẹ lati lọ ati iye ọdun kannaa lati pada, eyi yoo jẹ ọdunrun miliọnu ọdun imọlẹ. Nigbati o ba si pada si orilẹ aye nihin, gbogbo ọdun irinajo naa yoo jẹ aadọta ọdun pere. Ronu lori eyi, wo bi imọlẹ ti yára to, o n rin ibusọ ọgọsanlemẹfa lọna ẹgbẹrun ni iṣẹju kanṣoṣo, ki ẹ si ro nipa iye biliọnu si triliọnu ọdun ti yoo gba eniyan lati lọ si ibẹ, ki o si pada. Ọgọfa tabi ọdunrun biliọnu ọdun imọlẹ. Eyi si jẹ lati de ibiti asopọ awọn irawọ ti Ọlọrun fi ọwọ Rẹ gbajọ sibikan wa, Oun si lee wa nibiti o ga níwọn aimọye ọdun imọlẹ ti ẹnikẹni ko lee ka si ibiti awọn asopọ irawọ naa wa, ti O si n wo wọn lati ibi-giga yi.

21 Lẹyinnaa, ọmọ ilẹ Russia kan sọ pe o n wa ni ibusọ bi aadọjọ, igba ibusọ ni ofurufu, o wipe, oun ko ri Ọlọrun kan tabi awọn angẹli Rẹ. Bawo ni irori eniyan ṣe lee kúrú to? Lẹyinnaa, ẹ ro nipa gbogbo aimọye ọdun biliọnu ati triliọnu wọnyi, iṣiro eyi si jẹ aadọta ọdun si ibiti a wa yi, ki ni ohun ti o ṣe, o ti wọ inu ainipẹkun lọ.

Wọn sọ pe arin-rin-ajo ofurufu kan ti o lọ soke, o wa nibẹ fun ọpọlọpọ wakati, o lọ fun ọpọlọpọ igba, igba mẹtadinlogun kaakiri agbaye, tabi ohunkohun ti o jẹ, wọn sọ pe ko tilẹ ... Akoko naa ko tilẹ to iseju aaya kan ninu ọjọ aye rẹ. O nlọ pẹlu akoko naa. Nitorina, ṣe ẹ rii, o ti wọ Ainipẹkun lọ. Eyi ni titobi Ọlọrun.

Ero wa ko lee loye bi Ọlọrun ti tobi to. Nigbati O ba si ṣetan lati fi ara Rẹ han, O n ṣe bẹẹ ni ọna yẹpẹrẹ, O nlo ohun yẹpẹrẹ lati ṣee, ohun ti o ṣe yẹpẹrẹ ju.

22 Dafidi, o dabi ẹniti ... Ninu gbogbo awọn ọmọkunrin Jesse mejeeje, oun ni eyiti a mu wa siwaju wolii naa gbẹyin. Eeṣe, awọn ẹbi rẹ paapa tilẹ lee fi ṣe yẹyẹ, wọn ko lee ro pe Dafidi kekere, ti o ni irisi aginju, ti ejika rẹ ko gún régé, ẹniti irisi rẹ jẹ ti ara oko, wọn ko lee rò pe o lee jẹ ọba Israẹli. O lee ma jọ ọba niti irisi loju awọn eniyan naa, ṣugbọn o daju pe oun yoo ti jọ ọba loju Ọlọrun ... O yàn an ni ọba botiwu-kori. Ṣe ẹ rii, Ọlọrun mu eyiti o kere ju ninu ẹbi Dafidi, tabi ninu ẹbi Jesse, lati fi i ṣe ọba. Ohun ti gbogbo aye ti kọ silẹ ... Jesse ti ran an lọ lati ṣe amojuto awọn agutan rẹ. O mu akọbi rẹ ọkunrin wa, ẹniti irisi rẹ lokun, boya o tilẹ lee duro daradara, ki o si dabi ọba Israẹli, eyi si ni ẹniti wọn ro pe irisi rẹ yoo dara pẹlu ade lori rẹ, eyi ni ẹniti yoo wọ aṣọ igunwa ọba ti o si lee gbe ọpa ọba, tabi ohunkohun ti a o ṣe si ọba. O dara ni oju awọn eniyan.

23 Ṣugbọn wolii naa, pẹlu ororo ni ọwọ rẹ, pe, “Iwọ ko ha ni omiiran” O si mu wọn wa, ni ọkọọkan, titi ti o fi sọ nikẹyin pe, “Iwọ ko ha ni omiiran?”

O wipe, “Mo ni ọkan, ṣugbọn boya oun ko lee yẹ fun ohunkohun. O jẹ eniyan ti irisi rẹ ko tilẹ jọ ti ọba, o wa ninu aginju lọhun to n da ẹran.”

Wolii naa wipe, “Lọ pe e wa.” Kete ti oju wolii ti a misi naa ri i, o tu ororo naa lee lori, o si sare lọ pade rẹ pe, “Eyi ni ẹniti Ọlọrun yan,” ṣe ẹ ri i. Ṣe ẹ rii, ki i ṣe itanna aye lo nfihan nigba-gbogbo. Ọlọrun lo n ṣe iyan.

Nipa oore-ọfẹ ni O yan wa, bẹẹ ni a mọ riri eyi ni owurọ yi. Oun ko si lo awọn ohun meremere aye. Onirẹlẹ patapata ni o lee jẹ iranṣẹ Kristi, O n lo eniyan ti o fẹ lati ṣe e.

24 Ọlọrun ta ororo lee, ṣe ẹ rii, O yan ohun kekere. Bayi, Eeṣe ti Ọlọrun yan Bẹthlẹhẹmu kekere? O dabi ẹnipe awọn ilu ti o ga ju eyi lọ wa, ti o yẹki a bi Ọba, Ọba nla, Ọba awọn ọba si.

Bi o ti maa n ri, nigbati a ba fẹ ṣe ohun kan lori ilẹ aye nihin, a maa n fẹ ki o ṣẹlẹ nibi giga, a maa nlo ohun to n dán ju laye, ti eniyan lee ro, a maa n gbe e lọ si ibi giga julọ, ki a si naa owo pupọ, ati siṣe amulo awọn ohun ti o tobi julọ. Bi a ti maa n ṣe e niyi.

Ṣugbọn Ọlọrun ki i ṣe Tirẹ ni ọna yi. O maa nlo ohun ti ko ni itumọ, ki O lee fi ara Rẹ han ni alagbara, ki O lee ṣe e. Ti O ba lee mu alufa agba tabi eniyan ti a kọ pupọ ni ọjọ to n pe awọn apọsteli, ti O ba lee pe eyi dipo alaimọkan, pẹjapẹja ti ko ni imọ iwe, ti ko tilẹ lee kọ orukọ ara rẹ, wọn ko ba ti sọ pe, “Ah, eyi, ṣe ẹ ri i, imọ iwe rẹ lo ran ọ lọwọ.” Ṣugbọn Ọlọrun pe eniyan ti ko tilẹ lee kọ orukọ ara rẹ, ki O lee lo ohun ti o ni lọwọ, ohun ti O lee sọ di ohun elo, lati fihan pe Oun ni Ọlọrun. Nigbati a ba de ipele kan ti a ti loye pe a ko jẹ ohunkohun, lẹyinnaa, ti a bọ si ọwọ Ọlọrun, ti O si lee mọ ọ, ki O ṣe ọ bi O ti fẹ ki o ri. Ṣugbọn niwọn igbati a ba ni imọlara pe a ṣe pataki, a ko ni lee de ibikan pẹlu Ọlọrun. Iwọ ko tilẹ lee bọ si ọwọ Ọlọrun titi ti iwọ yoo fi loye pe iwọ ko ṣe pataki.

25 Ọkan ninu awọn ọmọbinrin mi kekere n bi mi leere ni ọjọsi nipa iṣe pataki ... Koburu, ti a n sọ nipa ọkunrin pataki naa, àárẹ ti wọn ṣe iku pa laipẹ, inu wa si bajẹ fun eyi. Mo si wipe, “Koburu, eniyan pataki ni.” Awọn iwe iroyin maa n sọ nipa rẹ nigba gbogbo, ẹrọ tẹlifisan pẹlu ṣe afihan rẹ, aimọye biliọnu lọna biliọnu owo dọla ni o ná ijọba lati ṣe afihan iyẹn. Ninu eyiti, o dara lati ṣe bẹẹ, ojuṣe ti wọn niyẹn. Ṣugbọn mo sọ pe ... Oniwaasu ijọ afedefọ kan ni ilu Carolina, nibiti eniyan kan ti wọle, ọmuti, pẹlu ibọn ilewọ rẹ, ti o pe fun iyawo rẹ, ti o si fi ibọn naa pa oniwaasu yi, lẹyin eyiti o pa iyawo ara rẹ, ti o si gba ẹmi ara rẹ, ibi kekere ni

wọn kọ iroyin diẹ nipa iṣẹlẹ yi, si ẹyin iwe iroyin wọn. Jẹki n sọ eyi fun ọ, arakunrin, ẹnitowu ki o jẹ, “Njẹ iwọ fẹ mọ bi o ti tobi to,” Mo sọ fun ọmọbinrin mi kekere naa pe, “ki ika rẹ bọ inu ládugbó omi, ki o si fa a yọ pada, ki o si gbiyanju lati wa iho ti ika rẹ wọ.” A ko jẹ ohun kan. Ẹnikan lo ṣe pataki ju, eyi si ni Ọlọrun. A gbọdọ ranti eyi pe, Oun ni.

26 O dabi wipe ti wọn ba fẹ ... eniyan ti nwa ibikan ti a o bi Ọba naa si, oniruuru ilu ẹsin ti o gaju eyi lọ ti o si jẹ ibi itan fun ọba naa, dipo Bẹthlẹhẹmu kekere yi. Awọn ilu, fun apẹrẹ, ilu Shilo. Ilu Shilo ni akọkọ gbe apoti ẹri si, a mọ, bi a ti mbọ lati Jordani si iha Palẹstini, si ibiti a gbe apoti ẹri naa ka fun ijọsin si i fun igba akọkọ. Tabi ni Gilgal; Sioni, Sioni ti i ṣe ilu nla bẹẹ ni Gilga.

Tabi ilu nla-ni, ibi iwuri tii ṣe olu-ilu, Jerusalẹmu, nibiti olu ile iṣẹ awọn agbekalẹ wa, awọn olu ile-iṣẹ wọn, o dabi ẹnipe wọn tilẹ ti pese ibikan fun wọn ni Jerusalẹmu, fun ìbí Ọba nla naa, ti wọn ba n fẹ ibikan, ibi itan, tabi ibiti o ta-yọ pupọ. Jerusalẹmu ni olu-ile iṣẹ awọn ẹsin wa, niti ẹsin wọn ti Ọba maa n wa. O wa sibẹ gẹgẹ bi aṣoju ẹsin wọn ... Nigbati O sị se bẹẹ, dipo ki wọn o wa àyè fun Un ni Jerusalẹmu tabi nibikan ninu awọn ilu iṣenbaye wọn, a bi i ni Bẹtlẹhẹmu, ilu ti o kere ju ninu awọn ilu yooku. “Iwọ ko ha kere ninu ọmọ alade Judea? Ṣugbọn ninu rẹ ni Baalẹ kan yoo ti wá ti yoo jẹ olori awọn eniyan Mi.” Ilẹ Jerusalẹmu ti i ṣe ilu iwuri ati awọn ilu yooku ni a kọ̀ silẹ.

27 Tabi, boya wọn ko ba ti lo ọkan ninu awọn ilu nla, ilu nla bii Hebroni, Kadeshi, tabi Romoth-gileadi, ọkan ninu awọn ilu aabo wọnni, nitoripe Oun ni yoo jẹ ibi Ìsádi wa. Ti awa yoo ba gbiyanju lati ṣe ninu ero wa, a ko ba ti lo, boya, “koburu, nisisiyi, ti Ọba nla yi ba mbọ wa, ẹniti yoo jẹ Aabo wa, a ni lati bi i ni ọkan ninu awọn ibi ìsẹ̀nbáyé ti wọn ti o jẹ ilẹ ìsádi, bi Ramoth-gilẹadi, tabi Kadeshi, tabi ọkan ninu awọn wọnni.” A ko ba ti gbiyanju lati ro bẹẹ ninu ọkan wa.

Ṣugbọn, ṣe ẹ ri i, Ọlọrun ni ọna miran to n gba siṣẹ Rẹ. O mọ bi a ti lee ṣe nkan ni ọna ti o yẹ. Ati nisisiyi, nipa ero Ọlọrun ati iranlọwọ Ọlọrun, a o gbiyanju lati sọ idi ti eyi fi ṣẹlẹ, nitoriti ohun gbogbo n siṣẹ nibamu pẹlu eto nla Ọlọrun. Mo si fẹ ki ẹyin eniyan ni ilu Phoenix nihin, ati agbegbe rẹ gbiyanju lati loye eyi. Ki ẹ ranti pe, Ọlọrun mọ ohun to n ṣe, ṣe ẹ rii. O si maa nlo ohun kekere lati ṣe e. Nitoripe, ti O bạ se nkan nipasẹ ohun ti o tayọ ... Ọlọrun ki i ṣe nkan bayi, ko ti i ṣe bẹẹ ri ninu gbogbo itan iṣẹlẹ inu Bibeli. Ọlọrun ki i ṣe pẹlu, ko ti i fi igbakan ṣe bẹẹ ri, ko ti i lo ẹgbẹ eniyan lati ṣe ohunkohun ri. Ọlọrun maa nlo eniyan kọọkan. Iwọ nikan, iwọ gẹgẹ bi ẹnikan ni yoo bạ se papọ. Ọlọrun ki i yi eto Rẹ pada, nitoripe eto Rẹ akọkọ, O gbọdọ maa tẹsiwaju pẹlu eto naa.

28 Ni ọjọ Noah, eniyan kan ni O ni, eyitiṣe Noah. Ni ọjọ ti O ko awọn ọmọ Israẹli jade, eniyan kanṣoṣo ni O lo, eyi ni Mose. A mọ pe Datani ati ọpọlọpọ awọn eniyan yooku gbiyanju lati ro o pe, koburu, aṣẹ kannaa ni awọn ni pẹlu Mose, ati bẹẹbẹẹ lọ. Ẹ mọ ohun ti o ṣẹlẹ si wọn. Ni ọjọ wiwa Oluwa, ọjọ Johanu Onitẹbọmi, ati oniruru awọn yooku. Ọlọrun ni eniyan kanṣoṣo to n ba siṣẹ papọ. O si n ṣe pẹlu wa loni ni ẹnikọọkan, ki i ṣe bi ẹgbẹ́. Ẹnikanṣoṣo! O ku si iwọ ati emi lọwọ, nipa bi a o ti duro niwaju Ọlọrun. Nitoripe, O n ṣe pẹlu iwọ ati emi gẹgẹ bi ẹnikan, ki i ṣe gẹgẹ bi ẹgbẹ ti a wa ninu rẹ, bẹẹ ni ki i ṣe bi ijọ ẹlẹyamẹya ti a jẹ ara rẹ, ṣugbọn pẹlu iwọ ati emi gẹgẹ bi ẹnikan.

29 Nisisiyi, Joshua, ninu ojuṣe rẹ lati pin ilẹ naa, o fi ilẹ kekere yi fun Judah. Ọpọlọpọ yin, mo ni awọn Iwe Mimọ kan ti mo kọ silẹ nihin nipa ibiti ilu naa wa, ṣugbọn gbogbo wa ni a mọ iyẹn, ibiti o wa ni kọrọ kan. O si jẹ àyè kekere ti wọn fifun Un, Joshua, bi o ti n pin ilẹ naa, o fi ilẹ naa fun ẹ̀yà Judah.

Nisisiyi, nigbati Israẹli la odo Jordani ja, bayi ẹ gbiyanju lati ri eyi, nigbati Israẹli la odò naa ja si ilẹ naa, ilẹ ileri naa, obinrin keferi kan wa ti a mọ si Rahabu, eyiti i ṣe panṣaga. O si beere fun aanu, o ti ri aanu gba, o ri aanu gba niwọn igbati o duro si abẹ okun ti a fi ba a da majẹmu. Eyi si ni ọna kanṣoṣo ti o fi lee ri aanu gba. O jẹ ami kan, ami ti a fifun un.

A ni Ami kan loni, pẹlu, a si wa labẹ aabo niwọn igba ti a ba duro si abẹ okùn majẹmu ti a fifun wa, ẹjẹ Jesu Kristi. Gẹgẹ bi ẹnikan, ki i ṣe bi ẹgbẹ eniyan, ikọọkan ni a gbọdọ duro labẹ okùn majẹmu Ẹjẹ Jesu Kristi.

30 Lẹyinnaa, Rahabu yi, lẹyin ti a da a si, o mu gbogbo awọn eniyan rẹ wọle, ohun gbogbo ti o wa labẹ okùn majẹmu naa ni a gbala. Bi igbati Ọlọrun binu ni ilẹ Egipti. Gbogbo ohun ti o wa labẹ ẹjẹ naa ni a gbala. Gbogbo awọn ti o wa labẹ okùn majẹmu naa ni a gbala. Gbogbo ẹniti o ba wa labẹ Ẹjẹ Jesu ni a o gbala, gbogbo ẹniti ko ba si ni abẹ rẹ ni yoo ṣegbe, ti a si ti mura rẹ silẹ fun iparun. A si ri i nisisiyi, pe ni siṣe eyi ... Bẹẹ ni a loye rẹ nipa itan pe Rahabu yi dá ọ̀rẹ́ pẹlu balogun ilẹ Israẹli kan, nko mọ orukọ rẹ bayi, ninu awọn ọmọ ogun Israẹli. O si fẹ ọkunrin yi nigbẹyin. Wọn si gbe ni, agbegbe ilu kekere yi, ọmọ rẹ Salmon si ni ẹniti o tẹ ilu Bẹtlẹhẹmu dó. Ṣe ẹ rii, keferi ni i ṣe pẹlu rẹ lati ibẹrẹ, keferi, Rahabu panṣaga.

31 Bayi, a ri i pe Salmon ni o tẹ ilu Bẹthlẹhẹmu kekere yi do. O si bi Boasi. Boasi si ni ẹniti o fẹ Rutu, ẹniti i ṣe keferi miran. A si n tẹle iran yi bayi. Rutu jẹ ọmọ ilẹ Moabu, o si fẹ Boasi, o si wa si ilẹ kekere yi ni akoko

ìkórè barli. Ah, ti a ba ni akoko ni owurọ yi, lati sọrọ lori eyi, n o jẹ iyawo mi ni aṣọ mẹta, nigbẹyin. Ṣugbọn bi o ti yẹ fun wa lati duro lori akori naa!

32 Naomi duro fun ijọ atijọ, ẹniti o lọ nitori ìyàn, o lọ si ilẹ awọn ara Moabu, bi igbati a fọ́n Israẹli ka, kaakiri orilẹ ede agbaye. Bi o si ti pada wa, o wa pẹlu Rutu, ọmọ Moabu, o si de ni akoko barli, ibẹrẹ akoko ikore barli. Eyi ni pe ijọ keferi n pada si ọdọ Ọlọrun ni akoko barli lẹẹkansi i, iru afiwe arẹwa wo ni eyi. Lẹyinnaa, oun ati Boasi fẹ ara wọn, wọn si bi ọmọ wọn olokiki, Obedi, nibẹ, oun pẹlu si bi ọmọ nibẹ. Lẹyinnaa, ọmọ rẹ, ọmọ, ọmọ, ọmọ rẹ, Jesse, ti inu Obedi wa. Nibẹ ni oun pẹlu ti bi Dafidi, ọmọ rẹ, nihin ni Dafidi ọba ti jade wa.

33 Ẹ wo bi eyi ti mbọ wa bayi. Lati ọdọ Rahabu panṣaga, ọmọkunrin rẹ, ni o tẹ ilu naa do. Lati ilu naa ni Boasi, ẹniti o mu keferi miran wa. Lati ọdọ Boasi ni Jesse ti wa. A si bi Dafidi fun Jesse. Dafidi, ni a ta ororo le lati ọwọ wolii Ọlọrun naa wa, lati jẹ ọba Israẹli. Gbogbo awọn nkan Ẹmi wọnyi ti a fi pamọ kuro loju araye, gbogbo rẹ lo n ṣẹlẹ ni ilẹ Bethlehemu kekere yi. Ṣe ẹ rii, bi Ọlọrun ti n ṣe niyi.

34 Bayi, mo ni igbẹkẹle pe Ẹmi Mimọ yoo wa nihin bayi lati fun yin ni oye ti o tọna, pe Ọlọrun ki i ṣe pẹlu awọn nkan nla wọnyi. O jẹ nipa Ẹmi Rẹ.“Ki i ṣe nipa agbara, ki i ṣe nipa ipe, bikoṣe nipa Ẹmi Mi ni Oluwa wi,” ṣe ẹ rii. Ọlọrun n sisẹ ninu Ẹmi laarin awọn eniyan. Ṣe ẹ rii, pẹlu awọn ipilẹ nla wọnyi, O lee wa si ilu yi nikan. Ibẹ nikan ni a ti lee bi i. Ọlọrun n tẹle ila Rẹ kannaa. Ọlọrun maa n ṣe eyi nigba gbogbo. Ọlọrun maa n tẹle ila Ọrọ Rẹ. Ọlọrun ko lee kọ ẹ̀yìn si Ọrọ Rẹ labẹ botiwukori, ki O si tun maa jẹ Ọlọrun, O ni lati duro ti Ọrọ naa. Oun ko lee fi eyi silẹ. Loni, awọn igbagbọ asan wa ati bẹẹbẹẹ lọ n mu wa kuro ninu Ọrọ naa, a ni awọn ẹkọ adamọ ati ohun gbogbo ti a fi sinu Ọrọ naa, eyiti o ba ohun gbogbo jẹ. Ṣugbọn Ọlọrun ko lee fi ila Ọrọ Rẹ silẹ. Otitọ ni Ọrọ Rẹ, nigba gbogbo, nitoripe Oun ni Ọrọ naa. Ọlọrun ati Ọrọ rẹ jẹ ọkan.

35 Bayi, a ri nihin bi Bethlehemu kekere yi, eyiti eniyan ko kà-sí, ilu kekere ti aye ko kà-sí pupọ, o jẹ eyiti o kere ju ninu awọn ilu, ko si ẹniti o kiyesi i. Sibẹ, Ọlọrun ninu eto Rẹ, ti pinnu pe ilu naa ni gbogbo awọn nkan wọnyi yoo ti ṣẹlẹ. Bayi, awọn ẹni Ẹmi yoo loye eyi, nitoriti wolii naa sọ nihin pe, ṣe ẹ ri i, wolii naa sọ pe, “Iwọ Bẹthlẹhẹmu Judea, iwọ ko ha kere laarin awọn ọmọ alade? Ṣugbọn lati inu rẹ ni Baalẹ kan ti yoo dari awọn eniyan Mi, Israẹli yoo ti jade wa.” Wolii naa, ero wolii naa ni eyi.

Kiyesi awọn ohun ẹmi wọnyi, Ẹmi Mimọ n dari awọn nkan wọnyi. Ko ni itumọ kan, ohun towu-ki aye sọ ninu gbogbo ẹwa rẹ. Kiyesi i, Ẹmi Mimọ ni Ọrọ naa, ibẹ ni O ti n wa.

36 Ki ni a o sọ nipa igbati Jobu ku, ti o si ti tọka si ibiti wọn o sin oun si? Abrahamu de, Abrahamu ra ilẹ kan, nibiti a sin aya rẹ si, Sarah. Bẹẹni Abrahamu, nigbati o ku, o fẹ ki a sin oun si ẹba Sarah. Abrahamu bi Isaaki. Isaaki, nigbati o ku, o fẹ ki a sin oun pẹlu Abrahamu. Isaaki bi Jakọbu. Jakọbu ku, ni ilẹ Egipti, ṣugbọn o mu Josẹfu (ọmọkunrin rẹ ti i ṣe wolii) bura fun oun, pẹlu ọwọ rẹ ti o gbe le egungun itan rẹ ti o ti yẹ̀, pe ko ni sin oku oun si ilẹ Egipti. Eeṣe? O wipe, “Ẹ gbe oku mi lọ si ilẹ naa, nibẹ ni ki ẹ si sin mi si.” Bẹẹni Josẹfu, nigbati o ku ni ilẹ Egipti, o sọ nipa lilọ, ati bi Israẹli yoo ti lọ nibamu pẹlu asọtẹlẹ naa, ṣugbọn o wipe, “Ẹ ko egungun mi kuro ni ilu yi.” Eeṣe? Wọn mọ pe eso akọso ti ajinde yoo ṣẹlẹ ni ilẹ naa, nitoriti Jobu sọ pe, “Emi mọ pe Oludande mi mbẹ laaye, atipe nikẹhin ọjọ Oun yoo duro ni ori ilẹ aye; ati ìdin inu mi ba pa ara mi run, sibẹ ninu ẹran ara mi ni emi o ri Ọlọrun.”

37 Wọn mọ pe akọso eso ajinde mbọ wa lati ilẹ ileri, ki i ṣe lati ilẹ Egipti. Wọn jẹ ẹni ẹmi, wolii ni wọn. Nigbati Jesu si ku, ni ọjọ Ẹti Rere, ti O si jinde ni owurọ ọjọ Ajinde, eyitiṣe owurọ ọjọ Aiku ti o tẹlee, Bibeli sọ bẹẹ, “Ọpọlọpọ ninu awọn eniyan mimọ ti o sùn ninu erupẹ ilẹ, wọn dide, wọn si jade wa kuro ninu iboji, wọn wọ inu ilu lọ, wọn si goke lọ sinu ogo pẹlu Rẹ.” Eeṣe? Awọn wolii naa ti wọn mọ ibiti o yẹki a sin wọn si, si ilẹ naa, ati ni akoko naa. A fi i pamọ kuro ni oju awọn ọlọgbọn, ṣugbọn awọn mọ ... Wọn wo iha ti Ẹmi. Akọso eso ajinde yoo ti ilẹ Palẹstini wa, ki i ṣe lati ilẹ Egipti.

Bẹẹ ni ọrọ ri loni, ẹyin ọrẹ. Ọpọlọpọ awọn eniyan n di awọn ohun aye mu, awọn ilana nla kan tabi ohun kan bẹẹ. Ẹ sin mi sinu Jesu, nitoripe awọn ti o wa ninu Kristi ni Ọlọrun yoo gbe soke pẹlu Rẹ ni ọjọ ajinde. Nko si bikita nipa ohun ti aye yoo sọ, bi wọn yoo ti gbiyanju lati mu ohun gbogbo dán to. Ninu Kristi ni, awọn ti o wa ninu Kristi ni Ọlọrun yoo jinde pẹlu Rẹ. Awọn ẹni Ẹmi maa n loye awọn ohun Ẹmi wọnni.

38 Nihin ni wolii naa sọ pe, “Iwọ Bẹthlẹhẹmu kekere, iwọ ko ha kere ninu awọn ọmọ alade Judah? Ṣugbọn ninu rẹ ni a o ti mu Baalẹ yi wa,” ki i ṣe lati inu olu-ilu nla naa ti o jọ ara rẹ loju, ki i ṣe lati inu ilẹ ijọ ìṣènbáyé tabi ohun kan, nibiti ijọ Mẹtọdisti, ijọ Baptisti, ijọ Alagba, ijọ awọn onigbagbọ to n fi ifedefọ ṣe ijẹri Ẹmi Mimọ, tabi omiiran ti bẹrẹ.“ Ṣugbọn lati inu eyiti o kere ju ninu awọn wọnyi, lati ilu kekere ti a ko kà-sí ni n o ti mu eyi wa, alaṣẹ ti yoo sakoso awọn eniyan naa.”

Ṣugbọn ni oni, a fẹ sọ pe, “Awọn baba wą se eyi, awọn baba wa se iyẹn.” Ṣe ẹ ri i, Ọlọrun kọ ikọọkan wọn silẹ. Ọlọrun maa n ṣe ohun ti O wu u. Ẹ kiyesi ila Ẹmi naa, ẹ kiyesi i ohun ti Iwe Mimọ sọ. Wọn jẹ alaimọkan si iyẹn. Ṣugbọn, ṣe ẹ ri i, Iwe Mimọ lo tọna. Nigba-gbogbo, ni Ọlọrun maa n tọna.

39 A ta ororo le Dafidi lati ọwọ wolii nla yi wa, lati jẹ ọba. Ko si iyemeji pe Samuẹli, wolii nla yi mọ awọn nkan wọnyi siwaju akoko. Ibẹ si ni a ṣe ileri pe iru Ọmọ ẹmi yi yoo ti wa ... Nitoriti Ọlọrun ṣe ibura kan, pe, Oun yoo gbe Kristi dide lati joko si ori itẹ Dafidi. Nibo ni a tun ti lee bi Kristi ju ilu yi lọ? Nibẹ ni a bi baba Rẹ si, baba-baba Rẹ, baba-baba-baba Rẹ, baba-baba-baba-baba-baba ... Rẹ igbaani. Ṣe ẹ rii, awọn eniyan Rẹ lati iran keferi wa, nihin ni a mu wọn wa. Nisisiyi, Bibeli sọ bẹẹ, Pe: Ninu orukọ Rẹ ni awọn keferi yoo ni igbẹkẹle."

40 A ni lati mu gbogbo rẹ wa, ki ẹ lee ri i. A o fẹ lati duro sibẹ fun igba diẹ, ki a si sọrọ lori rẹ, ki a si fi idi ti awọn Keferi, mo mọ pe awọn ẹni Ẹmi yoo loye eyi nisisiyi; nitoripe, bi o ti jẹ pe awọn iya wọn ni, ti ki i ṣe awọn baba wọn ni o ni i ṣe pẹlu iran Jesu. Bayi, nitoripe o jẹ obinrin - Iyawo. A o ka awọn keferi mọ ... Keferi yoo jẹ ara Iyawo. Awọn keferi, "Jesu yoo mu awọn eniyan wa lati inu awọn keferi fun orukọ Rẹ." Eyi ni Orukọ Rẹ. O mu iyawo fun ara Rẹ wa lati inu awọn keferi. Bi ọrọ naa ti ni lati ri niyi, obinrin wọle wa, ijọ ... Wọn jẹ keferi, awọn iya-iya lati iran inu Ọmọ naa wa.

41 Nisisiyi, bi Isaaki ti wa ni iran iru Ọmọ naa pẹlu. Bayi ẹ kiyesi eyi, a ri i pe Dafidi ni ileri ọmọ kan. Bayi, a kiyesi bi eyi ti dọgba pẹlu Israẹli ... Nigbati a ṣe ileri iru ọmọ fun Abrahamu, ohun ti yoo jẹ, pe lati inu iru ọmọ rẹ ni Olugbala nla yi yoo ti wa, atipe oun ni yoo jẹ baba gbogbo orilẹ ede. Iru ọmọ rẹ nipa ti ara, ni Isaaki lootọ, o si kuna. Ṣugbọn iru ọmọ rẹ nipa ti ẹmi, nipa igbagbọ ti o ni, ni Kristi wa si aye, eyiti O mu gbogbo orilẹ ede wa.

Koburu, nisisiyi, ohun kannaa dọgba nihin lẹẹkansii. Iru ọmọ Dafidi nipa ti ara ni Solomoni, o si pada sẹyin bi ti awọn iru ọmọ Abrahamu yooku. O pada sẹyin. Bẹẹ ni Solomoni pada sẹyin. O fẹ ọpọlọpọ iyawo, ohun akọkọ ti o ṣẹlẹ, wọn yi ọkan rẹ kuro lọdọ Ọlọrun. O lọ, o si pada sẹyin, o ku bẹẹ, o pada sẹyin. Israẹli ku ni ọna kannaa, o pada sẹyin.

42 Ṣugbọn a rii pe iru Ọmọ ẹmi yi, eyiti a ṣe ileri rẹ lati wa nipa iru ọmọ ti ara gẹgẹ bi iran awọn eniyan to n ti ara Abrahamu wa, ṣugbọn Ọba naa ti inu ileri ti a ṣe fun Dafidi nipa ti ẹmi. A si bi Dafidi ni Bẹthlẹhẹmu. A ta ororo lee ni Bẹthlẹhẹmu. O si di mímọ̀ si wa nigbana pe nigbati Olu-iru Ọmọ naa, ajogun itẹ rẹ, nigbati a bi i, ninu ilu yi kannaa, Bẹthlẹhẹmu kekere. "Iwọ ko ha kere laarin awọn ọmọ alade Judah, ṣugbọn lati inu rẹ ni Baalẹ kan yoo ti wa, ti yoo sakoso awọn eniyan mi."

43 Ninu ilu kekere yi, ibujẹ ẹran kekere, ibujẹ ẹran kekere ti o wa niha ibikan, nibẹ ni iho apata kan wa, ati lati ibẹ wa ni a ri ibujẹ ẹran kan ti a ṣi awọn ilẹkun rẹ kekeke silẹ, nibẹ ni a gbe Ọmọ Alade alafia, ti a bi sinu ibujẹ ẹran, ninu apoti koriko kekere ti a gbe si ibikan nibẹ, awọn igbẹ ẹran kún gbogbo ilẹ ibujẹ ẹran naa, ati bẹẹbẹẹlọ, ṣugbọn lati inu rẹ wa ni Ọmọ Alade nla kan, iru Ọmọ obinrin naa, lati ibẹ wa ni Olugbala araye ti jade wa, lati inu rẹ wa ni Jehofa funra Rẹ ti jade wa, ni irisi eniyan kan, O ti inu ibujẹ ẹran kekere naa ti a ri ni Bẹthlẹhẹmu jade wa. A ko bi i lati aafin ọba kan, a ko bi i si ile ọla; ṣugbọn O ti ibi irẹlẹ naa wa, sibi igbẹ ẹran ti a ko jọ sibẹ, a si fi aṣọ ọja wee. Bi àṣà ti fihan, a mu aṣọ ọja naa lati ara akọ maalu, nibiti wọn ti n fi i ṣe iṣẹ oko.

44 Awọn otoṣi! Josẹfu ati Maria, awọn mejeeji jẹ otoṣi pupọ, nihin ni wọn wa ninu ibujẹ ẹran kekere yi. Bi Ọlọrun ti rẹ ara Rẹ silẹ to! Awa si n gbiyanju lati pe ara wa ni eniyan nla. Ṣe ẹ rii bi Ọlọrun ti rẹ ara Rẹ silẹ, ti O si n lo awọn ohun ti a ko ka-si, ki O lee mu awọn ileri nla Rẹ ti O ṣe ṣẹ. Bi Jehofa kekere yẹn ti a tẹ si ibujẹ ẹran, ti a fi aṣọ ọja ti a fi irun akọ-maalu ṣe we, eyiti o gbọ̀n silẹ lati ọrùn akọ-maalu ti a fi ajaga si. A si fi eyi we Ọmọ Alade Alafia. Akiika! Tani awa jẹ nigbanaa? Ki ni o yẹki o ṣẹlẹ si wa? Ti Ọlọrun ba lee rẹ ara Rẹ silẹ bẹẹ, ko ha yẹki awa pẹlu rẹ ara wa silẹ lati di iranṣẹ Rẹ, ti Oun bạ se iru nkan bi eyi? Ṣe awa ko lee gbagbe ipo ọla nla wa, ati awọn ohun aye yi, ki a jọwọ wọn silẹ, ki a si rẹ ara wa silẹ niwaju Rẹ ni akoko Keresimesi yi? ... Ki a fi imọ-oore wa han si i nipa ibi yẹn ati irẹlẹ naa, nipasẹ ki a rẹ ara wa silẹ lati gba Ọrọ Rẹ. Ohun towu ki igbagbọ asan wa sọ, Ọrọ rẹ lo ṣe pataki. Ohun ni Ọlọrun yoo tẹwọgba, Ọrọ Rẹ, à ní Ọrọ Rẹ nikan.

45 Bayi a ri i pe, ibujẹ ẹran kekere yi, ibẹ ni a ti kọ orin Keresimesi akọkọ lori ilẹ aye, a si kọ ọ lati ẹnu awọn angẹli. Ro nipa eyi! Orin Keresimesi akọkọ, ki i ṣe pe a kọ ọ nibẹ pẹlu Kaiafa, ki i ṣe ninu awọn ijọ arẹwa kan lori ilẹ aye, nibiti pasitọ nla kan wa, ṣugbọn ni ibujẹ ẹran kan ni Bẹthlẹhẹmu, eyiti o kere ju laarin awọn omọ alade. Ṣugbọn orin Keresimesi akọkọ ni a kọ lati ẹnu awọn angẹli ni ilu Bẹthlẹhẹmu kekere-ni. Ṣe ẹ ri ohun ti mo n sọ?

Botiwu-ki o jẹ otoṣi to, botiwuki o kere to tabi ki o ma jẹ nkan, Ọlọrun lee lo ọ, ti iwọ yoo ba gba A laye lati ṣe bẹẹ. Ọlọrun fẹ ọ... Iwọ ko ni lati jẹ ọmọ ẹgbẹ nla kan, tabi ọmọ ẹgbẹ ilana kan, tabi ẹgbẹ kan, tabi ohunkohun ti o lee jẹ, eyi ko ni itumọ kan si Ọlọrun. Iwọ ni Ọlọrun fẹ! Ti iwọ ba si ... ti o ba ni imọlara pe o tobi, mu imọlara naa kuro ni aye rẹ. O ni lati mu un jade. Iwọ wipe, "Koburu, mo ni oye Ph.D, LL.D." Iyẹn yoo mu ọ jinna rere kuro lọdọ Ọlọrun. Gbagbe ohun naa. Pada wa si ọdọ Ọlọrun. Pada wa si inu irẹlẹ Ẹmi, ki o si fẹran Ọlọrun, ki o gba Ọrọ Rẹ.

46 "Ti ẹyin ba n gbe inu mi, ti Ọrọ mi si n gbe inu yin, ẹyin yoo beere ohunkohun ti ẹ ba fẹ, a o si fifun yin."

Ọlọrun ṣe ileri eyi. “Ti ẹyin ba sọ fun oke yi pe, 'Ṣidi,' ti ẹ ko si ṣiyemeji ni ọkan yin, ṣugbọn ti ẹ gbagbọ pe ohun ti ẹ beere fun yoo wa si imuṣẹ, ẹ lee ri ohun ti ẹ beere gba.” “Ẹnikẹni ti o ba gba mi gbọ, iṣẹ ti emi ṣe ni oun yoo ṣe pẹlu. Eyiti o ga ju eyi lọ ni oun yoo ṣe, nitoriti Emi nlọ si ọdọ Baba mi.” Iru ileri wo ni eyi!

47 Ohun kan wa ti ko tọna nibikan. Ohun ti a maa n gbiyanju lati ṣe ni ki a dori Rẹ kodò, ki a si mu ohun nla kan wa lati inu ijọ wa, ki a fi ododo ati itannaa arẹwa si i, a sị se idibajẹ ajọyọ Keresimesi. Eyi dara! Ti a ba lee mu itannaa atọwọda wa kuro nibẹ, ti a si da irẹlẹ pa da si ọkan wa! Ti a ba lee mu irẹlẹ pada sinu Keresimesi, si ohun ti o yẹki o jẹ! Ki i ṣe ọjọ itaja, ki i ṣe itanna ati afihan Baba Keresimesi! Ṣugbọn ki a pada sinu ijọsin si Ọlọrun, Ẹlẹda ohun gbogbo, Ẹniti o wa sinu ibujẹ ẹran, ti a si bi i bi ọmọ-ọwọ, Ọlọrun ti a sọ di eran ara, ti O si gbe laarin wa! Ti a ba lee pada sinu eyi, ki a kuro ninu itanna arẹwa ati awọn ohun gbogbo bẹẹ. Ọlọrun ki i ṣe pẹlu gbogbo eyi.

48 Iwọ wipe, “Koburu, emi jẹ ọmọ ẹgbẹ ti o tobi julọ.” Iyẹn yoo mu ọ jinna rere kuro lọdọ Ọlọrun ju ti atẹyinwa lọ. Iwọ sọ pe, “Emi n ṣe eyi, ati iyẹn.” Iyẹn yoo mu ọ jinna rere si i.

O ni lati rẹ ara rẹ silẹ, titi ti iwọ yoo fi ri eyi, titi ti, “Ti ẹyin ba n gbe inu mi, ti Ọrọ mi si n gbe inu yin, lẹyinnaa, ni ẹyin yoo beere ohun ti ẹ ba fẹ.” Ohun ti a n gbiyanju lati ṣe, kete ti Ọlọrun ba ti bukun wa diẹ, a maa n gbiyanju lati dori ohun gbogbo kodo, ki a sọ ara wa di olokiki ninu rẹ, ti a o fi ni orukọ nla kan, ki a sị se ju ẹnikeji wa lọ. Eyi bẹrẹ ni ọna yi, ati ni ọna yẹn, Ọlọrun yoo si fi gbogbo rẹ silẹ. Ohun ti a nilo loni ni Ẹmi Mimọ ti a tu-jade lakọtun si ọkan awọn eniyan ti o ni irẹlẹ. A nilo Keresimesi tootọ, ibi-ìbí-tuntun. Ti ẹ ba lee loye pe ẹ ko jẹ ohun kan bikoṣe ibujẹ ẹran! Ọlọrun ko lọ si Jerusalẹmu, si Shiloh, tabi Ramoti-gileadi, O wa si ibujẹ ẹran to n rùn. Jẹki Ọlọrun ... Iwọ yoo loye ninu ara rẹ pe iwọ ko jẹ ohun kan bikoṣe ibujẹ ẹran to n rùn. Ṣugbọn ki i kaa bọ, ṣi ilẹkun ọkan rẹ silẹ fun Un, nigbati awọn ibi nla wọnyi ati awọn gbọngan nla n kọ Ọ silẹ, ṣi ilẹkun ibujẹ ẹran ọkan tirẹ silẹ ki o si jẹki Jehofa wọle sinu rẹ, ki o si kiyesi ohun ti yoo ṣẹlẹ, nitoripe Oun ni Ọrọ naa. O wipe, “tị eyin ba n gbe inu mi, ti Ọrọ mi si n gbe inu yin.” Oun ni Ọrọ naa. Jẹki O wọ ọkan rẹ wa, ki o si kiyesi ohun ti yoo ṣẹlẹ. Lẹyinnaa ni ki o bere ohun ti o fẹ, a o si fifun ọ.

Bẹẹni, ibẹ ni a ti kọ orin Keresimesi akọkọ lati ẹnu awọn angẹli, ni ọpọlọpọ ọdun sẹyin.

49 [Arakunrin kan fedefọ. Ẹlomiran sọ itumọ ede naa.] Amin. Bayi, a mọ pe iṣẹ naa gbọdọ ṣe pataki pupọ, ti Ọlọrun fẹ ẹ sọ iyẹn, bibẹẹkọ, Oun ko ni sọrọ laarin iwaasu lati ṣe iru nkan bi eyi. “Ẹ rẹ arayin silẹ labẹ ọwọ Ọlọrun,” eyi ni iṣẹ naa ti a ran si wa. Bayi, Baba wa ọrun, a mọ pe tiRẹ ni gbogbo ọgbọn, O si maa n ṣe ohun gbogbo bi o ti yẹ. A gbadura pe Iwọ yoo ṣe e nisisiyi, ki eyi lee jẹ iṣẹ Rẹ ti O ran si awọn eniyan naa, ki a lee rẹ ara wa silẹ lootọ, gbogbo wa, ki a si wa si abẹ ọwọ Ọlọrun alagbara. A fi ara wa le Ọ lọwọ, Baba, ki Iwọ lee fi eyi fun wa. Ni orukọ Jesu, Omọ Rẹ. Amin.

50 Bayi, lati maa ba ọrọ mi lọ, mo n sọrọ nipa igbati a kọ orin Keresimesi akọkọ, eyiti a kọ lati ẹnu awọn angẹli ni ilu Bẹthlẹhẹmu kekere. Ibẹ ni a gbe bi gbogbo awọn eniyan nla wọnyi. Ibẹ ni a bi Ọba naa ti a ṣeleri si. Ọba ti a ṣeleri wa si ibẹ. Bayi, ... lati ṣe kiakia bayi, ki n ma baa da yin duro. Ileri naa, ọrọ naa niyi, ọrọ ti a pe ni “Bẹthlẹhẹmu.” Ẹ jẹki a fọ ọ si wẹwẹ. Mo ti fi akọsilẹ diẹ silẹ ki n ma baa pẹ. Bayi, Bẹthlẹhẹmu. Ọrọ ti a pe ni B-e-t-h tumọsi “ile.” E-l tumọsi “Ọlọrun” ninu ede Heberu. E-l-h-e-m tumọsi “ounjẹ.” Bẹthlẹhẹmu, tumọsi “ile Ounjẹ Ọlọrun.” Ohun ti ọrọ naa tumọsi niyi.

Awọn ọrọ, awọn orukọ, ni itumọ. Ọpọlọpọ ko gba eyi gbọ, ṣugbọn otitọ ni. Ti orukọ ko ba ni itumọ, eeṣe ti orukọ Abram ni lati yipada si Abrahamu? Eeṣe ti a yi Sarai pada si Sarah? Eeṣe ti a yi Saulu pada si Paulu? Eeṣe ti a yi Simoni pada si Peteru? Ṣe ẹ rii, gbogbo nkan wọnyi ni o ni itumọ, ohun gbogbo ni itumọ.

51 Orukọ ti a pe ni Bẹthlẹhẹmu tumọsi “ile ounjẹ Ọlọrun.” Bayi, bi eyi ti ṣe dede si Jesu, ẹnitiṣe Ounjẹ Iye Ainipẹkun. Kristi ni Ounjẹ Iye. Gbogbo wa ni a gba eyi gbọ, a bi bẹẹkọ? Bawo ni Bẹthlẹhẹmu ti ṣe dede to nibẹ, ile ounjẹ fun gbogbo agbaye, Oun si jẹ ile ounjẹ iye Ainipẹkun. Idi niyi ti a fi gbọdọ bi Ọba naa nibẹ. O sọ ninu Iwe Johanu Mimọ ori kẹfa ẹsẹ karundinlogoji pe, “Emi ni Ounjẹ Iye ti o ti ọdọ Ọlọrun wa, lati ọrun. Awọn baba yin jẹ manna ni aginju, gbogbo wọn si ku. Ṣugbọn Ounjẹ yi, ti eniyan kan ba jẹ Ounjẹ yi, oun yoo wa laelae.” Lẹyinnaa, Jesu ni Ounjẹ Iye, bẹẹ ni Ounjẹ Iye ni lati wa lati Bethlehẹmu. Oun ni Ounjẹ Iye wa fun irinajo naa, bi O ti jẹ si awọn ọmọ Israẹli. Ọlọrun fi ounjẹ fun Israẹli lati awọsanmọ wa fun irinajo wọn, bi wọn ti n rin irinajo naa lati ibiti wọn ti fi Egipti silẹ si ilẹ ileri naa. Ounjẹ, ni gbogbo oru, o maa n jabọ lati awọsanmọ bi ojo. Ọlọrun si fun wa ni Ounjẹ Iye fun irinajo wa, eyiti O ti Bẹthlẹhẹmu wa, ile Ounjẹ Ọlọrun. Ṣe ẹ rii bi o ti yẹki o ri? O gbọdọ jẹ ibi orukọ naa ti a pe ni, Bẹthlẹhẹmu, “ile Ounjẹ Ọlọrun.” Lẹyinnaa bawo ni a o ṣe bi i ni Jerusalẹmu? Bawo ni a ṣe lee bi i ni Ramoti-gileadi? Ṣe ẹ rii, O wa si ibiti orukọ Rẹ wa, “ile Ounjẹ Ọlọrun.”

52 Ah, kiyesii, Israẹli gba ounjẹ ọtun ni gbogbo aṣalẹ, eyito n ti ọrun wa fun irinajo wọn. Kristi ni Iye wa, Ounjẹ Iye, lojoojumọ ni a si n gba imisi ọtun lati ọdọ Kristi wa, lati ọrun, Ẹmi Mimọ n sọkalẹ wa sori onigbagbọ lojoojumọ. Ounjẹ ọtun!

Iriri ana, ọpọlọpọ wa ni a n gbe nipa iriri ana. A ko gbọdọ ṣe iyẹn. Iriri oni ni a nilo! Eyi ni ohun to n ṣẹlẹ si

awọn ijọ wa, wọn n gbe nipa iriri ti John Wesili, nipa iriri ti Dwight Moody, Finney, Sankey, Knox, Calvin, ọpọlọpọ awọn akọni igbaani. Wọn n gbe nipa iriri naa. Ṣugbọn, ẹ ranti pe, ounjẹ ti o sọkalẹ, ti wọn si gbiyanju lati fi pamọ di ọjọ keji, o maa n bajẹ, idin maa n wọ inu rẹ, ati awọn tanwiji kekeke. Eyi si ni ohun to n ṣẹlẹ loni, awọn kànga ti wọn ti bajẹ, wọn n jẹ ounjẹ atijọ ti o ti bajẹ.

53 A gbọdọ ni ohun ti o jẹ ọ̀tun lati ọdọ Kristi, Ọrọ Rẹ loni fun akoko yi, ṣe ẹ rii. Oun to sọkalẹ lojoojumọ lati ọrun si ori onigbagbọ. Oun ni Bẹthlẹhẹmu wa, ile Ounjẹ Iye Ainipẹkun. A bi Kristi ni Bẹthlẹhẹmu, O si di ile Ounjẹ Iye Ainipẹkun Ọlọrun. Oun ni Ounjẹ Iye, Oun ni Bẹthlẹhẹmu wa. Kristi ni Bẹthlẹhẹmu wa. Ounjẹ ti ara ni a pe ni ọpa iye. A n pe ounjẹ ti ara, bi burẹdi fulẹfulẹ wa ati awọn nkan ti a ni, a n pe wọn ni ọpa iye. Jesu ni Ọpa Iye Ọlọrun, Ounjẹ Ọpa Iye fun Iye Ainipẹkun. Bi a ti n pe ọpa iye ni ounjẹ, Jesu, bi Oun ti jẹ Ounjẹ Iye, Oun ni Ọpa Ounjẹ Iye Ainipẹkun ti Ọlọrun si wa, ṣe ẹ rii.

54 A ko lee lọ, ohun kan gbọdọ ku, ki awa lee jẹun. Ni owurọ yi, nigbati ẹ ba jẹun, ẹda kan ti o ku ni ẹ jẹ. Ti ohun kan ko ba ku, ẹ ko lee yè, nitoripe ẹ lee wa laaye nipa ohun ti o ti ku nikan. Ti ẹ ba jẹ ẹran, ẹran kan lo ku. Ti ẹ ba jẹ ẹran ẹlẹdẹ, ẹlẹdẹ kan kan ti ku, lootọ. Lẹyinnaa, ti ẹ ba jẹ ẹran maalu, maalu kan ti ku. Ẹ wipe, “Ṣugbọn emi n jẹ burẹdi.” Eyi tumọsi pe irugbin ọka kan ti ku. “Eeṣe, emi n jẹ ewebẹ.” Awọn ewebẹ naa ku ki o to jẹ wọn. Eniyan ko lee wa laaye bikoṣe nipa ẹda kan ti o ku, ọna kanṣoṣo ti eniyan fi lee wa laaye ni.

Lẹyinnaa, ti ẹ ba lee wa laaye nipa ti ara, nipaṣẹ ẹda to kú nikan, ohun kan gbọdọ kú ki iwọ lee wa laaye ninu ara, melo-melo ni ohun kan ni lati ku, ki iwọ lee wa laaye fun ainipẹkun! Kristi ku ki a lee wa titi ainipẹkun. O si di ile Ounjẹ Iye Ainipẹkun Ọlọrun, ti awa n gba, lakọtun, ni gbogbo wakati ọjọ, ti O n ti ọdọ Ọlọrun sọkalẹ lati ọrun, gẹgẹbi Ẹmi Mimọ, O n fi ounjẹ fun ọkan wa ti ebi n pa bi a ti n joko papọ ninu ọrun. Oun ni Bẹthlẹhẹmu wa.

55 Lẹyinnaa, gbogbo ọmọ Ọlọrun ti o jẹ onigbagbọ tootọ ni a bi ni Bẹthlẹhẹmu pẹlu Rẹ. Ti Kristi ba jẹ Ounjẹ Iye, ti a bi ni Bẹthlẹhẹmu, eyitiṣe ile Ounjẹ Iye, nigbana, ẹnikọọkan awọn onigbagbọ tootọ ninu Kristi ni a bi ninu Kristi, a bi wọn ni Bẹthlẹhẹmu Ọlọrun. Amin. Lẹyinnaa, ki i ṣe Jesu nkan ni a bi ni Bẹthlẹhẹmu, a bi emi naa ni Bẹthlẹhẹmu, a bi iwọ pẹlu ni Bẹthlẹhẹmu. Bawo ni eyi ṣe lee ṣẹlẹ? Ni ilu Phoenix nihin ni Arizona, ni owurọ yi ni gbọngan Ramada, a lee tun ọ bi ni Bẹthlẹhẹmu Ọlọrun, ile Ounjẹ Iye Ainipẹkun. Jẹ ounjẹ naa, ki o si wa titi laelae!

56 Eeṣe ti o jẹ Bẹthlẹhẹmu kekere? Ni oni, “Eeṣe ti o jẹ akojọpọ awọn gbarayilẹ mimọ? Eeṣe ti o jẹ eyi, iyẹn tabi omiiran?” Awọn eniyan ko mọ ohun ti o jẹ.

Ṣugbọn Ẹmi n ṣe afihan Rẹ. Ọrọ naa n fihan. Oun ni afihan Ọrọ Ọlọrun. A ni iye nipaṣẹ Kristi, ati Kristi nikan. Awọn ẹgbẹ ti a gbekalẹ, awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ wa, awọn iyatọ ti a ni laarin wa, wọn maa mu wa kuro lọdọ Ọlọrun. A ni ọna kanṣoṣo si ọdọ Ọlọrun, eyi si jẹ nipasẹ Jesu Kristi. Ko si ọna miran ti a fi lee wa nipasẹ alufa kan, ko si oniwaasu kankan, ko si ilana kankan tabi ohun miran, Jesu Kristi ni, ati Oun ti a kan mọ agbelebu. Oun ni Ounjẹ Iye Ọlọrun, a si bi wa sinu Rẹ. Ti O ba si jẹ Ounjẹ Iye Ọlọrun, nigbana, Oun ni Bẹthlẹhẹmu. Bi a ba si bi wa sinu Kristi, a bi wa si Bẹthlẹhẹmu, ninu Kristi Jesu, a n joko ninu ọrun, a n jẹ ẹ. A n jẹ Jesu! Tani Oun i ṣe? Oun ni Ọrọ naa, “Ni atetekọṣe ni Ọrọ wa, Ọrọ si wa pẹlu Ọlọrun, Ọlọrun si ni Ọrọ naa.” Nigbati a ba lee joko pẹlu ilepa kan, Ọrọ Ọlọrun, ti a si n bọ́ ara wa pẹlu Ọrọ naa, a wa ni Bẹthlẹhẹmu Ọlọrun nipa ti Ẹmi, a n jẹ Ounjẹ Ẹmi Ọlọrun, ọkan wa yoo si maa ṣe “Amin!” si Ọrọ Ọlọrun kọọkan. A o maa gbadun Ounjẹ angẹli ti o ti ọrun wa yi.

57 Nigbati O ba sọ pe Ami wọnyi ni yoo maa ba awọn ti o gbagbọ lọ.“ Ẹkọ adamọ tabi ijọ ẹlẹkọ adamọ lee sọ pe, ”Ah, ko ri bẹẹ. Ṣugbọn eniyan tootọ ti a bi ni Bẹthlẹhẹmu, yoo sọ pe, “Amin!”

“Iṣẹ ti Emi ṣe ni ẹyin pẹlu yoo ṣe.” Awon ijọ ẹlẹkọ adamọ yoo sọ pe “Akojọpọ iji-ara ni.” Ṣugbọn olugbe Bẹthlẹhẹmu yoo sọ pe, “Amin,” nitoripe o tẹ ẹ lọrun pe Ounjẹ angẹli ni.

“Ti ẹyin ba n gbe inu mi, ti Ọrọ mi si n gbe inu yin, ẹ o beere ohun ti ẹ ba fẹ, a o si ṣe fun yin.” Amin.

Ah, awọn eniyan giga ati ọlọgbọn ko lee ri i. A n di igbagbọ asan ti awọn alagba fifun wa mu, to bẹẹ gẹẹ ti a ni lati ko kaadi ati ohun gbogbo miran jọ lati wa si ori pẹpẹ. Awọn wọnyi ko tọna! Nipa rírẹ ara rẹ silẹ nikan ni o fi lee wa si ori pẹpẹ Ọlọrun. Wa si ile Ounjẹ Iye Ọlọrun, eyitiṣe Jesu Kristi, ki o si maa gbe titi laelae niwaju Rẹ, ki a si gbe ọ soke nibi giga ninu ọrun ninu Kristi Jesu, ki a maa jẹ ninu Ọrọ naa. Iyẹn ni Bẹthlẹhẹmu Ọlọrun.

58 Melo ninu wa ni a wa ninu Rẹ ni owurọ yi? Eniyan melo lo ṣetan lati gbagbe igbagbọ asan wọn, eniyan melo lo ṣetan lati gbagbe ẹkọ adamọ ti o ṣe atako Ọrọ naa? Eeṣe ti awa ko lee ni isọji? Eeṣe ti a o bẹrẹ eyi? Ki lo ṣẹlẹ si ijọ awọn onigbagbọ to n fi ifedefọ ṣe ijẹri Ẹmi Mimọ? O ṣe adamọ ara rẹ. Bẹẹ ni. Iwọ ko lee ṣe adamọ Pentikọsti. Ẹ lee da ẹgbẹ ti o wu yin silẹ. Ṣugbọn Pẹntikọsti jẹ ibukun, agbara Ọlọrun ni. Ti o ba si jẹ Pẹntikọsti tootọ, ki yoo fi ẹkọ adamọ dipo Ọrọ naa. Yoo di Ọrọ naa mu. Bẹẹ ni, nitoriti a ti ṣe ikọla aya rẹ kuro

ninu aye ati ohun ti ṣe ti aye. O duro le Ọrọ Ọlọrun nikan, o si gbaagbọ. A wa ni Bẹthlẹhẹmu, a jẹ èrò si ijọba Ọlọrun. A n jẹ Ounjẹ Iye Ainipẹkun Ọlọrun. Eyiti a bi, Ọlọrun, Ounjẹ , ti a bi ni Bẹthlẹhẹmu, lati di Ounjẹ Iye ti Ẹmi, ti Iye Ainipẹkun, ni ile Ọlọrun. Akiika. A bi wa ni Bẹthlẹhẹmu, a wa nibẹ ni owurọ yi, nigbati a bi wa ninu Jesu Kristi, nitoriti O jẹ Bẹthlẹhẹmu Ọlọrun. Jesu ni Ile Ounjẹ Iye Ainipẹkun Ọlọrun.

59 Oun ni omi ti a nilo fun irinajo naa pẹlu. Bayi, a mọ pe Oun ni Omi naa. Bi ti awọn ọmọ Israẹli ninu irinajo wọn; Wọn lu apata kan, bẹẹ ni ounjẹ sọkalẹ lati ọrun, ṣugbọn a lu apata kan ki wọn o lee mun lati inu Rẹ wa ki wọn o fi lee wa laaye ninu irinajo naa. Ọlọrun lu apata kan, tabi O mu ki Mosẹ se bẹẹ, Wolii Rẹ, o lu apata naa. Ki ni eyi tumọsi? O ṣi apata naa. Kristi ni Apata naa. Njẹ ẹyin gba eyi gbọ? O dara. Lẹyinnaa, ti wolii naa ba ṣi apata naa ki iye lee ti inu Rẹ jade wa, nigbana, ti o ba jẹ apata naa, loni, a nilo Ẹmi Mimọ ninu eniyan kan ti yoo lu Apata naa lẹẹkansi, amin, ki o si mu Ọrọ naa jade wa, nitoripe Oun ni Ọrọ naa!

60 A ti ya sinu ẹkọ adamọ, a si ti mu adagun omi lati inu kànga idibajẹ wa. Ohun ti a nilo loni ni ṣiṣi Ọrọ naa ti O wa laaye, ti O fihan pe O jẹ ọkannaa lana, loni, ati titi laelae. Oun ko lee kuna! Wọn lee pee ni àwòṣe-ọpọlọ, wọn lee sọ ohunkohun ti o ba wu wọn, tabi ki wọn pe e ni alupaida ti ẹmi, tabi eṣu, niwọn igbati Ọrọ naa n sun jade laisi idiwọ, ti O si n ṣe ohun ti O ṣeleri pe Oun yoo ṣe gẹlẹ, O jẹ orisun ni ile Dafidi lẹẹkansii, ni Bẹthlẹhẹmu, nibiti Jesu Kristi ti i ṣe ọkan naa lana, ati loni, ati titi laelae, si awọn olugbe Bẹthlẹhẹmu Rẹ pẹlu Rẹ, ti wọn n gbe ninu Rẹ, Oun ni Omi Iye fun wa ni irinajo naa bi awọn ọmọ Israẹli ti ni in.

61 Ọkan ninu awọn iriri Dafidi ti o ga, ti ẹ ba fẹ ka nipa rẹ ninu Iwe Samuẹli keji ori karundinlogoji, bẹrẹ lati ẹsẹ kẹẹdogun, a ri i ka nibẹ pe Dafidi, bi a ti bii ni Bẹthlẹhẹmu, sibẹ, o di alarinkiri. Ah, iru iṣẹlẹ wo niyi! Awọn Filistini gbe ibudo ogun dide nigbana, ni ilẹ naa, nitoripe Saulu, ọkunrin nla ti o mu awọn ọmọ Israẹli wọ inu ẹ̀ṣẹ̀ lọ, o si ti ṣubu kuro lọdọ Ọlọrun, o si ti di Ọlọrun, wọn si ti patẹ ibudo ogun lodi si i, awọn Filistini ṣe ibudo ogun yika Bẹthlẹhẹmu. Ati Dafidi, bi o ti n gbiyanju lati pada lọ si ile rẹ, oun ko lee ṣe bẹẹ, o wa ni aginju, nitoripe o ti di alarinkiri si awọn eniyan naa, nibẹ ni a ti lee kuro ni ilu.

62 Iru akawe arẹwa wo niyi nipa Kristi loni, ẹnitiṣe alarinkiri. Bẹẹni O jẹ. Bayi, ẹ lee sọ pe, “Eyi ko lee ri bẹẹ.” Koburu, ti ẹ ba gbagbọ ninu Bibeli, bẹẹ lori. Bibeli sọ pe, ni Igba Ijọ Laodekia, pe Kristi wa ni ita ijọ, O n kan ilẹkun, O n gbiyanju lati pada sinu ijọ Rẹ. Alarinkiri ni eniyan ti a ko fẹ, ti a si kọ silẹ. Ọrọ ati Ẹmi Mimọ ni a si ti kọ silẹ. Bẹẹ ni. Iwọ ko lee wọ inu ile lọ. Ti iwọ ba gba a, o ni lati jade kuro nibẹ lati gba a. O ni lati jade tọ Ọ lọ. Oun ko lee wọle wa. Wọn ti kun fun ẹkọ adamọ wọn to bẹẹ gẹẹ ti wọn ko ni fẹ ki o waasu awọn nkan wọnni; wọn ko ni fẹ ki o gba awọn nkan wọnni gbọ.

Wọn wipe, “Njẹ iwọ gbagbọ pe O jẹ ọkannaa?”

“Ah, ni ọna kan, O jẹ ọkan naa.” Bayi, iyẹn ki i ṣe gbigbe ni Bẹthlẹhẹmu. Rara, rara. Iyẹn ni lati maa mu ninu adagun omi kànga idibajẹ, ti o ti wa lati igba pipẹ, ounjẹ àná ti o ti bajẹ, eyiti o sọkalẹ lati ọpọ ọdun sẹyin. “Ki ni eyi ati iyẹn sọ nipa rẹ?” Wọn lee dara nigba ijọ ti wọn. Ọjọ miran ni eyi. Eyi ni ọjọ Oluwa! Eyi ni igba ijọ miran, ki i ṣe Igba Ijọ Filadefia. Eyi ni Igba Ijọ Laodekia. A kọ ọ silẹ, Kristi si ti di alarinkiri ninu ijọ Rẹ, a ti i jade. O ti di ajeji.

63 O lee sọkalẹ wa, ki O si siṣẹ laarin awọn eniyan naa, O siṣe ohun kannaa ti O ṣe nibẹ, ti O ṣeleri pe Oun yoo ṣe ni ikẹyin ọjọ, O fi ami kannaa han ati awọn ohun ti O sọ pe Oun yoo ṣe, bi o ti ri ni ọjọ Sodomu. A mọ ohun ti O ṣe si ijọ nibẹ.

A ri Billy Graham, bi o ti ri nigbana, ati awọn iranṣẹ yooku ti o lọ si awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ, ti wọn si n waasu nibẹ. Wọn si n pe wọn jade, wọn n sọ fun wọn lati gba Ọrọ naa gbọ ati lati kuro ni Sodomu.

64 Awọn ijọ Abrahamu ko si ni Sodomu, a ti pe wọn jade naa. Kiyesi angẹli naa, Oun ti O ṣe fun wọn nibẹ, fun ami, ti wọn mọ. A si lee ṣe ohun kannaa, awọn eniyan naa si wipe, “Ah, koburu, ẹ maṣe gba a gbọ.” Eeṣe? Eeṣe? Nitoripe wọn ti sọ Kristi di alarinkiri si ẹgbẹ wọn, wọn jẹ ajeji pẹlu rẹ, awọn onigbagbọ to n fi ifedefọ ṣe ijẹri Ẹmi Mimọ ati gbogbo wọn papọ. Nisisiyi, bẹẹ ni eyi jẹ Otitọ gẹlẹ. Mo mọ pe eyi ko rọrun, ṣugbọn ẹ fetisilẹ ... Ti o ba jẹ Otitọ, yoo báni-wí. Bẹẹ ni. O ni lati jẹ Otitọ.

65 Nisisiyi, bayi, ẹ kiyesi Dafidi, nigbati o wa loke lọhun, Dafidi la ala nipa iṣẹgun alagbara rẹ. O wa ninu iho apata, o n duro sibẹ, lẹyin lọhun, ni nkan bi ibusọ mẹẹdogun si ẹyin ilu. O wa, o si kiyesi eyi nibẹ, ilu olufẹ rẹ, nibiti a ti bi i, ati nibiti a ti ta ororo lee lati di ọba ati bẹẹbẹẹ lọ.

Awọn olugbe Israẹli, ni awọn ọjọ wọnni, wọn dabi ti ọjọ oni ni ilẹ Germany. Wọn ni ilu kekeke, wọn si maa n gbe ni ilu nla fun aabo, wọn maa n ko awọn agutan wọn ati awọn ohun ini wọn jade kuro ni orilẹ ede lati bọ wọn, wọn yoo si dà wọn pada. Ni aṣalẹ wọn yoo ko wọn lọ ibujẹ wọn.

66 Ati Dafidi, bi o ti n bojuwo ilu naa, o bẹrẹ si ranti awọn iṣẹ nla ti Ọlọrun ti ṣe nipasẹ rẹ, awọn iṣẹgun nla ti Ọlọrun ti ti ọwọ rẹ mu wa. Bi o ti ṣẹlẹ ni ọjọ kan nigbati o ni awọn agutan rẹ ni ori oke ti o wa, bi wọn ti dubulẹ ni papa oko tutu, ati bẹẹbẹẹlọ, beari kan wa, o si ki ọkan ninu awọn ọdọ agutan mọlẹ, o si n gbe e lọ. O si lee

lọ, o si pa beari naa. Ọlọrun fun un ni iṣẹgun nitoripe baba rẹ ran an lati ṣe amojuto awọn agutan naa. Eyi ni iṣẹ rẹ, tọju awọn agutan naa!

Ẹyin oluṣọ aguntan, eyi ni iṣẹ yin! Wọn si n jẹ ounjẹ aguntan, ki i ṣe ounjẹ atọwọda. Ounjẹ aguntan, Ọrọ Ọlọrun!

Ẹnikan wa, o mu ọkan ninu wọn, o si salọ. Ẹnikan wa, o mu ọkan, o mu un jade, o sa tọ ọ lẹyin. Kiniun kan wa, o si mu ọkan, o ṣa tẹlee. Ko duro titi ti o fi gba a silẹ.

67 Eyi lo fun un ni iṣẹgun nla naa ni ọjọ kan, nigbati o ri Israẹli ti gbogbo wọn n fadi sẹhin. Ṣe ẹ rii, Israẹli ti n gbọ nipa gbogbo ẹkọ adamọ ati ohun gbogbo, ti gbogbo wọn ni, gbogbo wọn ti lọ si ile ijọsin. Gbogbo wọn ni a ti kọ ni ilà. Gbogbo wọn ti lọ si ọdọ alufa ti alufa si ti sure fun wọn siwaju ki wọn o to lọ. Ṣugbọn nigbati akoko fifi ohun ti wọn jẹ han nipa Ẹmi de, gbogbo wọn di ojo, nitoriti wọn ri i pe ohun kan n ṣe atako. Wọn ko si ni igboya, wọn ko ni ohun ti a lee pe ni ọrọ igboya loni, wọn ko ni ọrọ bi “Lọ ki o si gba a.” Eyi ni ohun ti wọn ko ni. Wọn ko lee bọ́ si gbagede lati dojukọ òmìrán naa. Eeṣe? Ṣugbọn gbogbo wọn ni alufa ti gbe ọwọ le wọn, o si ti gbadura fun wọn. Wọn ti ni ìwúre mimọ lori aye wọn, wọn ti kunlẹ, boya alufa tilẹ ti tu omi mimọ le wọn lori fun ami ororo, tabi ohunkohun ti o lee jẹ, nibẹ ni gbogbo wọn si n duro si. Ṣugbọn nigbati atako naa ga to bẹẹ gẹẹ, wọn ko ni ohun ti wọn fi lee dojukọ ọ. Nibẹ ni Saulu n duro si, ẹniti a lee fiwé alakoso agba ijọ tabi bisọbu, o n duro sibẹ, o ga ju awọn ọmọ ogun rẹ lọ ni gbogbo ọna.

68 Bẹẹni Golayati ṣe ipenija kan, o si wipe, “Ti emi ba pa a, lẹyinnaa ni ẹyin yoo sìn wa. Ṣugbọn ti o ba pa mi, lẹyinnaa ni awa yoo sìn yin,” Ṣugbọn atako naa ga pupọ. Ika ọwọ rẹ kọọkan to iwọn inshi mẹrinla, ọwọ rẹ kọọkan yoo to iwọn mejidinlọgbọn. Ẹ wo iru ọwọ ti o ni! Abẹrẹ rẹ, ohun ija kan ti a npe ni abẹrẹ ti o ni, ati ọ̀kọ̀ ti o ni. Ki ẹ si ro bi ori rẹ yoo ti tobi to, yoo tobi to igba-nla. Bẹẹni yoo de ibori ogun, ti o to inshi kan tabi meji, ibori idẹ ti o fi bo ori ara rẹ. Ẹ wo ohun ija ogun rẹ, awọn ohun ija ogun ti ikọọkan wọn yoo to irin ferese nla, ninu eyiti o ti lee mi eemi, ki o si mi ara rẹ, bi awọn ohun ija ogun naa ti n siṣẹ niyi. Pẹlu aṣọ ogun ti o wọ sọrun, o ṣeeṣe ki o ti ni iwọn ti o to ọgọrun, tabi igba, niti eroja idẹ, ti o fi ṣe igbaya. Pẹlu abẹrẹ, o mu ọ̀kọ̀-ṣónṣó ni ọwọ rẹ, boya giga rẹ to iwọn ẹsẹ bata mẹrindinlogoji.

Ohun ti ọta lee ṣe nigbati o ba gba ọ mu. Ohun ti yoo ro pe oun lee ṣe, bi yoo ti fọn-nu! Pe, “Awọn ọjọ iṣẹ iyanu ti lọ. Iwọ ko lee lọ pẹlu iru nkan bi eyi.”

69 Ṣugbọn ọkunrin kekere kan wa, irisi rẹ jọ ti ara-aginju, ko tilẹ ni iriri ile ẹkọ Bibeli, ṣugbọn o ni iriri pe Ọlọrun si jẹ Ọlọrun bi ti igbaani. Ọlọrun n pa Ọrọ Rẹ mọ. Nihin ni o jade wa, Saulu si wipe “Ni suuru naa, emi yoo fun ọ ni oye imọ ìṣe.”

O gbe ibori ogun tirẹ lee lori, o si wuwo ju fun Dafidi to bẹẹ gẹẹ ti o fẹẹ le wọlẹ. Dafidi ko mọ ohunkohun nipa iyẹn. O wipe, “Emi ko mọ ohunkohun nipa awọn nkan bi eyi.” O wipe, “Emi ko mọ. Ṣugbọn mo mọ ohun kan, pe iwọ n bẹru lati ba òmìrán naa ja? Ẹ si duro sihin, ẹ n pe ara yin ni ijọ Ọlọrun alaaye, ẹ si jẹki alaikọla ọmọ Filistini yi, alaigbagbọ lasan, duro si gbagede naa, ki o si maa gberaga bẹẹ?” O wipe, “Emi yoo lọ dojukọ ọ!”

Ah, a nilo awọn eniyan bẹẹ loni, awọn eniyan ti wọn ti ni iriri!

70 Ki ni ohun ti o ṣe? Ki ni Dafidi kekere ti Bẹthlẹhẹmu ṣe? O jade lọ si gbagede ija naa lati ba òmìrán naa ja. Òmìràn naa fi bu ni orukọ oriṣa ilu rẹ (awọn oriṣa, ọpọlọpọ), o fi bu ni orukọ awọn òmìrán rẹ, tabi awọn oriṣa rẹ, o jade lọ sibẹ, o si sọ fun Dafidi pe, “Loni, emi yoo fi ọ̀kọ̀ mi mu ọ, emi yoo si fi̩ eran ara rẹ kọ si ori igi lati fi ọ bọ ẹyẹ oju ọrun.”

Dafidi wipe, “Iwọ dojukọ mi gẹgẹ bi Filistini, ni orukọ Filistini, pẹlu ohun ija ogun ati ọ̀kọ̀, ṣugbọn emi tọ ọ wa ni orukọ Oluwa Ọlọrun Israẹli.” Ki ni ohun ti eyi jẹ? Ọrọ naa! Ọrọ naa, “Emi yoo dojukọ ọ pẹlu Ọrọ naa.” O wipe, “Loni, emi yoo ge ori rẹ kuro ni ejika rẹ.” Òmìrán naa rẹrin ẹlẹya, o si n tọ ọ lọ. Dafidi ko si sa pada, oun pẹlu n tọ ọ lọ. Ibi kekere kanṣoṣo lo wa ti eniyan lee ri lara omiran naa, Ọlọrun si dari okuta Dafidi lọ sibẹ.

71 Dafidi, bi o ti n duro sihin bi alarinkiri, o n ronu nipa iyẹn, bi iṣẹgun nla ti ṣẹlẹ. Nigbana o gbọdọ ti maa ro nipa awọn orin ẹmi naa, bi o ti jẹ pe nigbamiran ni ori oke, yoo dubulẹ, yoo si ro nipa Ọlọrun. O wipe oun so ofin Rẹ mọ òpó ibusun oun ati si awọn ika ọwọ rẹ, ati si ibi gbogbo ti o ba lọ. “Emi ti gbe Oluwa ka iwaju mi, nigba gbogbo, a ki yoo mi mi.” O fi Ọlọrun si iwaju ara rẹ. Ati awọn iṣẹgun nla ti o ti ni! Nigbati o ba ni imisi, akọrin ẹmi ni, yoo fo soke, yoo mu gege rẹ, yoo si kọ awọn orin ẹmi naa silẹ, yoo si kọ wọn. Yoo wọ inu Ẹmi lọ, yoo jó, yoo jó, yoo jó ninu Ẹmi. Bi yoo ti wọ inu Ẹmi lọ to bẹẹ gẹẹ, yoo jó ninu Ẹmi nipa kikọ awọn orin ẹmi wọnni silẹ. O si nilati wa si inu oniruru orin ẹmi, bi i, “Oluwa ni Oluṣọ aguntan mi, emi ki yoo ṣe alaini. O mu mi dubulẹ ni papa oko tutu (Orin Dafidi ori kẹtalelogun), O mu mi lọ si iha omi didakẹ rọrọ. O tu ọkan mi lara. Ah, O mu mi lọ si ipa ododo Rẹ, nitori Orukọ Rẹ. Bi emi tilẹ n rin ni afonifoji ojiji iku, emi ki yoo bẹru ibi kan. Nitoriti Iwọ wa pẹlu mi.”

72 Bi o ti n ro nipa awọn nkan wọnni, o gbọdọ jẹ ọjọ ti ooru mu, orugbẹ n gbẹẹ, ooru mu un, o si n laagun. O lee wo afonifoji lati ori oke, ni ẹba ila-oorun tabi iwọ-oorun, tabi ila-oorun ni, ti ilu naa, nigbati o wolẹ ti o si ri ibiti gbogbo awọn Filistini naa, ti gbogbo wọn ṣe ibudo ogun yika. O ri kanga igbaani ninu eyiti o ti mun omi. Ah, o bẹrẹ si ro nipa owurọ ọjọ kan, nigbati yoo ko awọn agutan rẹ, ti yoo ko wọn lọ lati bọ wọn, yoo gba ẹba kanga yi kọja, nitoriti o jẹ ibi isun omi pupọ. Nigbana, yoo lọ sibẹ, yoo si mun omi, yoo mun omi, yoo fi omi fun awọn aguntan rẹ mun. Bi o ti jẹ ilu Bẹthlẹhẹmu, nibiti o ti fi omi fun awọn aguntan rẹ.

Nibẹ gẹlẹ ni Ọlọrun ti fi omi fun awọn aguntan Rẹ loni, lẹẹkansii, ni Bẹthlẹhẹmu lọhun, o jẹ omi tutu ti o mọ́ pupọ.

73 O ke jade, "Ti emi ba lee ri omi mun lati inu kanga naa lẹẹkansi!" N o wa si idanu duro bayi, ẹ fetisilẹ daradara. "Ti emi ba lee ri omi mun!" Ohun kan ke jade lati inu rẹ wa, Pe, "Ti emi ba lee mun lẹẹkansii lati inu kanga naa ni Bẹthlẹhẹmu." Ifẹ ọkan rẹ jẹ aṣẹ fun awọn ti wọn fẹran rẹ. Ẹ ranti, ọkan rẹ n pongbẹ fun omi lati inu kanga naa. Awọn ti wọn si fẹran rẹ, eyiti o kere ju ninu ifẹ ọkan rẹ, aṣẹ ni si wọn. A sọ fun wa nipa eyi ... mẹta ninu awọn ọmọ ogun rẹ parapọ, awọn eniyan nla. Ọkan ninu wọn pa ẹgbẹrin ọ̀tá, oun nikan. Ikeji fo sinu iho kan, o si pa kiniun. Ọkan mu ọpa, o si fi gba ọ̀kọ̀ kuro lọwọ ara Egipti kan, o fi ọ̀kọ̀ ara rẹ pa a, o si duro si papa lentili bẹẹ, o si pa ọdunrun layika ara rẹ. Awọn eniyan nla! Keferi ni wọn. Ẹ wo ibiti wọn ti wa.

74 Dafidi nihin jẹ afiwe Kristi, Bẹthlẹhẹmu, nitoriti Kristi jẹ Ọmọ Dafidi. Nihin ni o n duro si, o n sọkun fun omi lati inu kanga naa. Ifẹ ọkan rẹ si jẹ aṣẹ, mo sọ pe, si awọn ti wọn fẹran rẹ. Mẹta ninu awọn ọkunrin naa fa ida wọn yọ, wọn si ja titi de ibusọ mẹẹdogun, titi ti wọn fi de ilu naa ... Awọn ọkunrin naa jẹ akọni ologun (awọn Filistini naa, awọn miran ninu wọn tobi to meji omiran ninu awọn ọkunrin yi) ṣugbọn wọn jẹ, ọkunrin, akọni, ti wọn lee ja. Ọkan ninu wọn, oun nikanṣoṣo duro, o si pa ẹgbẹrin ọkunrin ti o yika ni ọjọ kanṣoṣo. Jagunjagun nla ni wọn, wọn ni igbẹkẹle ninu Ọlọrun. Wọn ni igbagbọ ninu adari wọn. Wọn si ja ogun de ibẹ, nigbati awọn kan ninu wọn n dojukọ ọta, omiran pọn omi ladugbo kan, wọn si ja pada ni iwọn ibusọ mẹẹdogun ti oniruru ọmọ ogun duro si, wọn si gbe omi naa tọ Dafidi lọ ki o lee mun.

75 Nihin ni a ti ri akawe Kristi, ati niti ọba oun ti ṣe jagunjagun, nitoripe O jà de iṣẹgun ni gbogbo irinajo naa. O ké okùn iku ọta. O ké okùn ọ̀tá ki awa lee ni Iye Ainipẹkun, Omi Iye Ainipẹkun. O la iku paapa kọja, O si fi ori ara rẹ ru iku, O si ku iku naa, O si jinde wa ki awa lee ni Iye Ainipẹkun. Oun ni Ọba ati Jagunjagun. Awa ko ṣẹgun, O ti ṣẹ ogun naa! Awa ko ṣẹgun iku, Oun lo ṣẹgun rẹ fun wa! Oun ni Dafidi wa ti ọjọ oni. O ṣẹgun iku. Ounjẹ ati Omi Bẹthlẹhẹmu.

76 Bẹthlẹhẹmu ni aarin-gbungbun. Ẹyin onimọ nipa itan mọ eyi, pe ohun ni aarin-gbungbun. O jẹ ile iyẹfun nla nibẹ, wọn n ṣe ọgbin nipa òjò atọwọda ati ohun bẹẹ. Wọn lee ṣe ogbin ọkà nla nibẹ. Nibẹ ni omi to daraju wa pẹlu. Ibẹ ni ibudo ounjẹ ati ibudo omi fun ilẹ Palẹstini.

Loni, iye ẹgbẹ eniyan towu ki a ni loni, bi iye awọn ti a n pe ni ara loni ti lee pọ to, ati ọna towu-ki wọn o wa, sibẹ, Kristi ni Bẹthlẹhẹmu onigbagbọ. Oun ni Ounjẹ ati Omi. Ijọ Mẹtọdisti, eyi dara fun yin; eyi dara fun ẹyin ijọ Baptisti, fun ẹyin ijọ onigbagbọ to n fi ifedefọ ṣe ijẹri Ẹmi Mimọ, ati fun ẹyin yooku. Ibikanṣoṣo ni gbogbo rẹ, eyi si ni Bẹthlẹhẹmu, nibẹ ni Ounjẹ ati Omi Iye ti san wa ... Bẹẹ ni.

77 Oun ni Ounjẹ wa, Ounjẹ ati Omi Ọlọrun fun wa. Oun ni aarin-gbungbun, ibikanṣoṣo ti o ti lee wa ki o si gba a, o jẹ lati ọdọ Rẹ. Ile Ọlọrun, ninu Ẹniti a n pe ni Jesu Kristi, Bẹthlẹhẹmu wa, Ounjẹ ati Omi Iye Ainipẹkun. Oun si ni Ọrọ naa ti a sọ di ara. Ọrọ naa niyi, Ounjẹ ati Omi Iye. Iwe Heberu 13:8 wipe, "O jẹ ọkan naa lana, ati loni, ati titi laelae." Eyi ni o sọ Ọ di Bẹthlẹhẹmu wa, ibi Ounjẹ ati Omi wa, ibi Iye Ainipẹkun kanṣoṣo.

78 Ẹ kiyesi Dafidi, bi o ti ri omi naa, ko mun un. O wipe, "Ki Ọlọrun ma jẹ. Eyi ni ẹjẹ awọn eniyan wọnyi ti wọn fi emi ara wọn wéwu." Lati jade lọ, ki wọn si mu omi naa tọ Ọ wa. Kiyesii! O tu u si ilẹ, fun ọrẹ ohun-mímu si Ọlọrun. Amin! Ẹyin eniyan ati ẹyin ara, ẹ ru igbagbọ yin soke fun iṣẹju kan nisisiyi. O kọ lati mun omi naa. O tu-u silẹ fun ọrẹ-ohun mimun si Ọlọrun.

Bawo ni eyi ti ṣe dede to pẹlu Iwe Johanu 3:16, "Nigbati Ọlọrun fẹ araye to bẹẹ gẹẹ, ti O fi Ọmọ bibi Rẹ kanṣoṣo fun-ni." Jesu, Ẹnitiṣe Omọ Alade Iye, O wa sihin, ko ni lati ku. O ṣẹgun iku funra Rẹ, O si tu Ẹjẹ Iye ara rẹ jade silẹ, amin, gẹgẹ bi ẹbọ fun ẹ̀ṣẹ̀ wa. Oun ni Apata wa ti a lu ni ori ilẹ, Ẹjẹ Rẹ ọwọn ti Ọlọrun fifun-ni.

79 Mo gbọ ti ẹnikan sọ ni aṣalẹ ọjọsi ninu iwaasu kan, ti o sọ pe wọn wa si ... Mo gbagbọ pe Billy Graham ni, ni aṣalẹ ana, a n kiyesi bi o ti sọ pe oun lọ si Ilẹ Israẹli, ti o si lọ si Palẹstini, o si sọ pe, "Mo wa lati gba awọn eniyan yin gbọ," ohun kan bẹẹ. Mo si fẹran bi o ti farahan lori eto agbaye naa ni aṣalẹ ana. Ọpọlọpọ yin kọyin si ọkunrin naa fun bi o ti ṣe eyi. Ṣugbọn, ẹ wo ibiyi, o duro siwaju gbogbo orilẹ ede naa nigbana. Ko si kó ọrọ naa jẹ, o duro lori ohun ti o gbagbọ gẹlẹ. Emi si fẹran rẹ fun eyi. O si wipe, "Emi lọ si Ilẹ Israẹli, mo si sọ fun wọn pe, "Emi n foribalẹ fun ọkan ninu awọn ọmọ yin, ni ede miran, bi eyi."

Mo ro o pe, “Billy, eyi jẹ iyanu. Emi yoo fẹ lati ri agbara Ọlọrun ti iwọ ni lati duro si aarin gbogbo awọn itanna Ilu-Ibajẹ wọnni, ti iwọ si n ṣe ijẹri nipa Jesu Kristi, ṣugbọn Oun ki i ṣe Juu.” Ọlọrun ni Jesu, ki i ṣe Juu. Ẹ ranti eyi, isun iru iye n ti ara ọkunrin wa. Oun ki i ṣe eniyan, Juu tabi keferi, Ọlọrun ti a da ninu ara ni. A ko gba wa la nipa ẹjẹ Juu tabi ẹje keferi, a gba wa la nipa Ẹjẹ Jesu Ọlọrun. Oun ni Ọlọrun, ko jẹ ohun miran bikoṣe Ọlọrun. Oun ki i ṣe Juu tabi keferi. Gbogbo wa ni a ti ṣegbe. O jẹ Ọlọrun. Otitọ niyi.

80 Emi ko sin Juu, Ọlọrun ni emi n sin nigbati mo ba n foribalẹ fun Jesu Kristi. Emi ko foribalẹ fun igbagbọ eke ìgbàdégbà kan tabi ohun kan ti a fi lelẹ nipa itan. Emi n foribalẹ fun Jesu Kristi, ifarahan Jesu Kristi nisisiyi, eyitiṣe Ọrọ Rẹ ti a fihan ni Igba Ijọ yi.

Ọlọrun ni gbogbo igba ijọ, ni abala Ọrọ Rẹ lati ibẹrẹ, ati nigbogbo igba ijọ naa ni o lọ, Ọlọrun maa n ran wolii kan ti a ta ororo le fun igba ijọ naa. Ni akoko Noah, ati ọjọ awọn yooku, nigbati Ọlọrun ṣe awọn ileri Rẹ. Nko bikita nipa ipo ẹmi ti ijọ wọ lọ, Ọlọrun maa n ṣe eyi, O maa n ran eniyan kan ti a ta ororo le. Nitoriti Ọrọ Oluwa maa n tọ awọn wolii wa. O si duro nibẹ, ikọọkan awọn wolii naa, ti a si dalẹbi nipasẹ awọn ẹgbẹ eniyan akoko naa, ṣugbọn o duro ti Ọrọ naa, o si mu ki Ọrọ naa wa laaye.

81 Jesu ni ẹkunrẹrẹ Ọrọ Ọlọrun, nitoriti O jẹ ẹkunrẹrẹ Ọlọrun ninu ara, ninu Rẹ si ni ẹkunrẹrẹ Ọlọrun n gbe. Ọlọrun gbe ninu Jesu Kristi. Ọlọrun wa ninu Kristi, O n ba araye laja si ọdọ ara rẹ. Ki i ṣe Juu tabi keferi, ṣugbọn Ọlọrun! Nibẹ ni O duro si, O n ṣe afihan ara rẹ. Bawo ni eyi ti ṣe dede to! A si gbọdọ ta ẹjẹ Ọlọrun silẹ, lati bo ẹjẹ Abẹli alaiṣẹ ti a ta silẹ mọlẹ, ki a lee rawapada. Oun ko gba ẹmi ara rẹ, Oun ko dị emi ara rẹ mu; O wipe, “Baba, njẹ o ṣe e ṣe fun agogo yi lati re Mi kọja? Ṣugbọn, ki i ṣe ifẹ ti Emi, jẹki ifẹ tiRẹ ṣẹ.” O jọwọ ara rẹ fun Ọrọ naa.

Ni oni, a lee ṣe ohun kannaa. Iwọ lee yan ẹkọ adamọ tirẹ, iwọ lee yan eyi-ati-iyẹn tirẹ, ki o si se ohunkohun ti o ba fẹ pẹlu rẹ; ṣugbọn iwọ lee sọ pe, “Ki i ṣe ifẹ ti emi, ṣugbọn ki ifẹ tirẹ ṣẹ.” Pada wa sinu Ọrọ naa ti i ṣe ti Ọlọrun. Mu gbogbo itanna rẹ ati Keresimesi, ki o sị se ohunkohun ti o wu ọ lati ṣe, ṣugbọn fi Jesu Kristi fun ọkan mi. Botiwu ki o rẹlẹ to, ati bi awọn eniyan ti fi ṣe ẹlẹya to, tabi ohun towu ki o jẹ. Kiyesi iwa ẹda rẹ̀, wo o bi o bạ se bi Jesu. Ti ko bạ se bẹẹ, maṣe fiwe Ọrọ yi, jọwọ rẹ silẹ; ki i ṣe Kristi, nitoripe Kristi ni Ọrọ naa.

Bayi a ri bi o ti ṣe dede to, Apata wa, ti a lu, Ẹjẹ Iye Rẹ tu silẹ, ijiya-ẹṣẹ fun ẹlẹṣẹ. Bẹthlẹhẹmu wa, omi, Ounjẹ ati Iye ti a fifun wa fun isọdimimọ awa alaimọ ati ẹlẹṣẹ.

82 Ah, ẹyin ọrẹ mi ẹlẹṣẹ, bawo ni ẹyin yoo ti ṣe kọ Ọ silẹ, iru irubọ bẹẹ, nipa aigbọn yin, nigbati Ọlọrun fi Ọmọ Rẹ kanṣoṣo fun wa, irubọ ẹṣẹ, pe ẹnikẹni ti o ba gba a gbọ, ti o gbagbọ ninu Rẹ, ma ba a ṣegbe, ṣugbọn ki o lee ni Iye Ainipẹkun? Bawo ni iwọ ṣe lee wọ inu Rẹ? Nipa Ẹmi kanṣoṣo ni a baptisi gbogbo wa sinu Bẹthlẹhẹmu kan, eyitiṣe Ọrọ Ọlọrun, eyitiṣe Kristi ti a fihan ninu ara fun igba ijọ yi.

Ati gbogbo ileri ti Bibeli fifun igba ijọ yi, O n duro fun wolii kan lati wa si oju-ri, lati ṣe afihan rẹ, O ṣe ileri eyi nibamu pẹlu Iwe Malaki ori kẹrin. Yoo si ṣẹlẹ. Botiwu ki awọn eniyan ro pe o jẹ iṣe omugọ to, yoo ṣẹlẹ botiwu-kori! Ọlọrun sọ bẹẹ! O ni agbara lati ... Ẹkọ adamọ wa ko ni gba a, ti ijọ wa ko ba ni gba a, Ọlọrun lee pada lọ si ibujẹ ẹran naa, O lee lọ si ibikibi ti O ba fẹ. Ṣugbọn ẹnikan yoo duro fun ohun ti a sọ fun ọjọ oni. Ohun kan ni lati ṣe afihan Rẹ. Ki yoo jẹ ẹgbẹ eniyan kan, pẹlu, ko ti i fi igba kan jẹ bẹẹ ri.

83 Ẹyin ọmọ, ọmọ ogun Rẹ, bi mo ti n wa si idanuduro. Nko fẹ da yin duro pẹ pupọ. N o danuduro nisisiyi, bi Oluwa ba fẹ. Agogo mọkanla ti ku iṣẹju marun, tabi iṣẹju mẹfa. Ẹ kiyesi eyi, Ẹyin ọmọ ogun, ẹyin eniyan nihin ti ẹ n jẹwọ pe ọmọ niyin! Njẹ ẹ mọ ohun ti Dafidi duro fun? Dafidi duro fun Kristi, Kristi jẹ Omọ Dafidi. Ẹ feti-silẹ nisisiyi, bi a ti n pari. Awọn jagunjagun keferi-ni, ọpọlọpọ wọn, ẹ kiyesi pe wọn wa lati ibi gbogbo, ṣugbọn wọn mọ pe alarinkiri yi ni ami-ororo Ọlọrun ni ori rẹ. Wọn mọ pe a ti kọ Dafidi silẹ lati ọwọ awọn eniyan rẹ, ṣugbọn wọn mọ pe ami-ororo naa wa lori rẹ. Wọn lee ri i. Nitorina ni wọn duro ti i, ni kíkú tabi ni yíyè! Wọn jẹ akọni, botiwu ki awọn eniyan ma gbaagbọ to.

Awọn eniyan tirẹ gangan lee jade. Wọn ko fẹẹ ni ohunkohun lati ṣe pẹlu rẹ. Saulu lee jade, olori awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ lee jade, wọn ko ni ohunkohun lati ṣe pẹlu rẹ, awọn igbimọ lee danu, o si di alarinkiri. Wọn ni lati lọ si ibikibi ti o ba lee lọ. O si wa ni ori-oke nibẹ, ṣugbọn awọn ẹgbẹ eniyan diẹ, ti i ṣe keferi ati bẹẹbẹẹ lọ, ni wọn korajọ sinu ẹgbẹ naa, ti wọn n wo ọkunrin naa, ti wọn si mọ pe yoo di ọba.

84 Bẹẹni o ri loni pẹlu awọn jagunjagun igbagbọ tootọ ninu Ọrọ naa, ti wọn mọ pe Ọrọ naa ṣeleri pe Jesu yoo pada wa. Awa ko ni ifẹ ninu aimọye miliọnu dọla ti eyi ati ti iyẹn. Mo ni ifẹ ninu ipadabọ Kristi Jesu. Ẹyin ọmọ ogun Ọlọrun. Ki lo n ṣẹlẹ si yin, bawo ni ẹ ṣe n duro loni? Nigbati a ri i pe Bibeli sọ asọtẹlẹ pe alarinkiri ni-loni, ti a le e jade kuro ninu ijọ Rẹ, ti a le e kuro ninu awọn ẹgbẹ gbogbo. Ẹ mọ eyi. Ko si idi lati maa fi eyi pamọ, otitọ ni eyi. Biblei sọ pe yoo ri bẹẹ. Ẹ jade kuro ninu ami ẹranko naa!

85 Ẹ wo awọn eniyan wọnyi! Wọn fa ida wọn yọ. Ki ni ohun ti eyi jẹ? Ifẹ ọkan rẹ ni omi tutu lati inu kanga

naa. Dafidi! Iru afiwe wo ni eyi jẹ fun ọjọ oni, Dafidi wa, Kristi, a mọ pe aye n pe e ni gbarayilẹ mimọ, a ti le e si apa kan, a pee ni alakata-kiti, ati ohun gbogbo bẹẹ, ijọ kọ Ọ silẹ. Wọn ni awọn ẹkọ adamọ ti wọn ati ohun gbogbo ti wọn la kalẹ fun Keresimesi bi wọn ti ṣe nigba akọkọ. A mọ eyi, ṣugbọn a mọ pe Ọrọ Ọlọrun jẹ otitọ nigba-gbogbo, a si gbọdọ mu Un ṣẹ. Ifẹ ọkan Kristi ni fun awọn eniyan, awọn ọmọ ogun, lati duro! Amin!

86 Ah, ẹ wa duro si iha mi, mo n duro si ibi ti ko rọrun. Mo peyin nija loni! Ohùn yi n lọ si ibi gbogbo lagbaye. Mo pe ẹnikan nija, ọmọ ogun ti o fẹran Jesu Kristi, ti o mọ pe a gbọdọ mu awọn nkan wọnyi ṣẹ loni, ẹyin ará, ẹ wa duro si iha mi ki ẹ si fa ida Ọrọ Ọlọrun yọ. Ẹ gbagbe nipa awọn kanga ofifo ati awọn omi adagun ijọ ẹlẹkọ adamọ ti ẹ n gbe ninu rẹ. Ẹ fa Ọrọ Ọlọrun ti o wa laaye yọ, ẹ jẹki a fun Jesu ni omi daradara ti Pẹntikọsti ti O ni imisi! Eyi ni ifẹ ọkan Rẹ loni, ki a pada si ojulowo Pẹntikọsti, ẹ pada sinu Ọrọ naa! A sọ asọtẹlẹ rẹ pe a o ṣe bẹẹ, ni ori kẹrin Iwe Malaki ... lati yi ọkan awọn ọmọ pada si ti awọn baba, lẹẹkansii. Tani yoo duro ni owurọ yi?

87 Bi ti Dafidi, a mọ pe Dafidi mbọ wa si ipo agbara. Jesu Kristi mbọ lati gba isakoso aye. O jogun aye, yoo di Ọba lori ilẹ aye. A ti kọ Ọ silẹ loni, O jẹ alarinkiri laarin awọn eniyan Rẹ. Nitoripe, O jẹ alarinkiri si gbogbo aye, nigba gbogbo lo maa n jẹ bẹẹ. Ṣugbọn loni, O jẹ alarinkiri si ijọ Tirẹ, wọn kọ Ọ silẹ, wọn fẹran awọn ẹkọ adamọ wọn, ati awọn eniyan olokiki wọn dipo Ọrọ Ọlọrun. Wọn ko ni jẹki O farahan. Wọn ko ni jẹki a waasu Rẹ ninu agbara Rẹ. Wọn kọ Ọ silẹ, bi Bibeli ti sọ pe wọn yoo ṣe ninu Iwe Ifihan ori kẹtadinlogun. Ki ni ohun ti wọn n ṣe? Wọn n lọ kaakiri loni, gbogbo wọn nlọ si inu igbimọ agbarijọ ijọ. Iṣe Katoliki ati ti awọn Alatako ti wọn n fimọ-sọkan, wọn n ṣe agbekalẹ aworan ati ami ẹrankọ naa. Awọn Alatako si n ṣubu sinu rẹ, awọn onigbagbọ to n fi ifedefọ ṣe ijẹri Ẹmi Mimọ, nibi gbogbo ni eyi ti n ṣẹlẹ. Awọn olokiki nlọ si ilu Romu, lati Pẹntikọsti, ti wọn si n pada wa, ti wọn n sọ pe, “Ibi Ẹmi ti o ga julọ niyi!” Ni ilu Texas ati nibi gbogbo, wọn n ṣe agbekalẹ ẹka wọn, wọn si n ṣe afihan òye ẹka wọn ati bẹẹbẹẹ lọ, ti wọn si mọ pe a ti ṣe àdàlú Ọrọ naa pẹlu ẹkọ adamọ!

88 Ah, ẹyin olugbe Bẹthlẹhẹmu! Hallelujah! Mo pe fun awọn eniyan, awọn ọmọ ogun ti ko bẹru. Nko bikita boya ẹgbẹrin duro si apa kan, ti ẹgbẹrun si n duro si apa keji, mo n fẹ awọn ọmọ ogun ti yoo lọ pẹlu mi, ti wọn yoo si fi ijakadi la ọna ni gbogbo ila awọn alaigbagbọ Filistini wọnyi. Agbarijọ igbimọ ijọ ti ṣe agbekalẹ ibudo ogun yika Ọrọ Ọlọrun, wọn n gbiyanju lati sọ Ọ di ẹkọ adamọ, ki wọn o si fi bọ awọn eniyan naa. Kanga kan wa, ìṣun kan wa ti a ṣi silẹ ni ile Dafidi, Bẹthlẹhẹmu, fun ẹ̀ṣẹ̀ ati aimọ. Arakunrin, ẹ̀ṣẹ̀ ni aigbagbọ ninu Ọrọ Ọlọrun!

Tani ... Ọmọ ogun ti o lee ri bibọ ijọba ẹgbẹrun ọdun? Ọmọ ogun wo ni o lee ri Ẹmi Mimọ nla yi to mbọ wa ni aworan Jesu Kristi, ara Kristi ti a lee fi oju ri, lati gba akoso aye lẹẹkansi, ẹ duro ti mi. Ẹ duro ti mi! Ẹ jẹki a la ọna wa kọja, nipa siṣẹgun ẹkọ adamọ awọn ijọ ẹlẹyamẹya wọnyi. Ẹ jẹki a wọ inu rẹ lọ! Jesu Kristi n ke fun ohun mímun ọ̀tun ti o ti inu kanga Pẹntikọsiti wa, ojulowo omi Pẹntikọsiti, ki i ṣe ẹgbẹ alagabagebe, ti wọn n ke, ti wọn si n pariwo lasan, Mo n sọ ni ojulowo baptisimu Ẹmi Mimọ, eyiti O mu Iye Jesu Kristi to n pada wa sinu eniyan.

89 Ẹ dariji mi ti mo ba payinlara. Rara, nko ṣe bẹẹ. Emi n ṣe eyi ni orukọ Jesu Oluwa. Ẹ pada wa! Ẹ duro, ẹyin ọmọ ogun akọni ti o ri Dafidi to n duro nigba wọnni! Jesu Kristi, alarinkiri ti a le kuro ninu Ijọ Rẹ, ti wọn fi ẹkọ adamọ wọn ti jade. Isun ọ̀tun kan wa to n duro lọhun. Amin. Agbara wa lati mu ki Ọrọ yi wa laaye lẹẹkansii, a sọ asọtẹlẹ rẹ ni ọjọ oni pe yoo ṣẹlẹ. Ọlọrun sọ pe yoo wa si imuṣẹ. O ni lati wa si imuṣẹ. Ẹ ko lee ṣe e ninu ẹgbẹ ogun ti ẹ wa nisisiyi. Ẹ n tẹ ibudo ogun funrayin, ẹyin ti ẹ pe ara yin ni onigbagbọ pẹntikọsti pẹlu awọn ẹgbẹ yooku, ẹ n mu Ọrọ naa wọ inu ẹkọ adamọ lọ.

90 Ẹyin eniyan Ọlọrun, nibo ni ida naa wa? Ọlọrun wa n pongbẹ fun omi mímọ́. Nko bikita ti yoo ba jẹ tikú-tìyè, ẹ jẹki a la aarin ibudo yi lọ. O ṣoro fun ọ lati daduro. Mo n beere fun awọn ọmọ ogun lati duro ti mi, lati duro ti Ọrọ naa! Oun ti Ọrọ naa sọ, sọ Ọ bi Ọrọ naa ti sọ Ọ. Nko bikita nipa ohun towu ki ohun miran sọ, duro ti i bi O ti sọ Ọ, nitori eyi ni ohun kanṣoṣo ti yoo la ọna naa. Ẹ jẹki a lọ si Bẹthlẹhẹmu, nibi isun Omi Ọlọrun tootọ.

“Ti ẹnikẹni ba ngbe inu mi, ti Emi pẹlu si ngbe inu rẹ ... Ti ẹyin ba n gbe inu mi ti Ọrọ mi si n gbe inu yin ...” Gbigbe ninu Rẹ ni, ki i ṣe ki a kan maa fo lati ibikan si omiiran, ki ẹ si maa ṣe ayipada kaadi idanimọ ọmọ ijọ yin lati ijọ ọkan si ti mejilọkan tabi si ti mẹtalọkan, ki ẹ si tun pada lọ si ijọ awọn Alagba, ijọ Luther. “Ẹ gbe ninu Mi (Oun si ni Ọrọ naa), ki Ọrọ Mi maa gbe inu yin! Ẹ maṣe bẹru ẹgbẹrin tabi miliọnu mẹjọ, Emi yoo wa pẹlu yin.” Mo n pongbẹ lati mun lati inu kanga naa lẹẹkansii.

91 Ọlọrun yoo ni awọn eniyan ti yoo mun lati inu kanga naa! Hallelujah! Ẹ lee ro pe aṣiwere ni mi, boya bẹẹ ni mo jẹ nigbana, mo jẹ aṣiwere nipa Jesu Kristi ati Ọrọ Rẹ. Ti aye yoo ba pe mi ni aṣiwere, jẹki a pe mi ni aṣiwere fun Ọrọ Rẹ. Emi ko tako awọn eniyan naa ti o wa ninu awọn agbekalẹ wọnni, agbekalẹ wọn to n kọyin si Ọrọ Ọlọrun ni mo lodi si. Ẹ jẹki a jagun, ẹyin ọmọ ogun, ẹ duro ti i! Ẹ jẹki a lọ sinu Kanga naa, Oun ni Bẹthlẹhẹmu.

Awọn kanga atijọ ni, agbarijọ awọn ijọ n ṣe agbekalẹ awọn eto wọn nisisiyi. Ẹ jẹki a ṣe imupada Ọrọ ọ̀tun Ọlọrun, ki i ṣe ti ijọ ẹlẹkọ adamọ. Ẹ maṣe jẹki a tẹle ẹkọ adamọ, iyẹn jẹ kanga adagun omi idibajẹ ti o ti sọkalẹ lati ogoji ọdun sẹyin, ogun ọdun sẹyin, ọgbọn ọdun sẹyin, tabi ni ọdun ti o kọja. Mo fẹ Ọrọ Ọlọrun ti a ṣeleri fun ọjọ oni. Iyẹn ni Omi ti O fẹ ki n mun, Ọrọ Ọlọrun ti ọjọ oni! O jẹ Bẹthlẹhẹmu, a kọ Ọ silẹ.

92 O jẹ ... Mo mọ, o da bi ẹ ti ro o, “Koburu, ti ...” Bẹẹ ni, bẹẹ ni eyi ri, wọn ni ero pe o yẹki a bi i ni Jerusalẹmu. Wọn ro pe o yẹki a bi i si ibiti Olu-ijọ ẹlẹkọ adamọ wọn wa. Ṣugbọn ko gba awọn ibẹyẹn wa. O wa si orukọ Bẹthlẹhẹmu, nitori ohun ti O jẹ niyẹn. Hallelujah! Jesu ko wa fun ijọ Mẹtodisti, Baptisti, Ijọ Alagba tabi ti awọn onigbagbọ to n fi ifedefọ ṣe ijẹri Ẹmi Mimọ. Iyawo lo mbọ wa fun, Jesu Kristi. Eyi ni ẹniti O mbọ wa fun. O lee ṣe ajeji si yin, ṣugbọn ẹ gba a gbọ!

93 Ṣe ẹ rii, awọn afiwe wọnyi, wọn ko lee wa ni ọna miran bikoṣe nipasẹ Ọrọ Rẹ. Ibẹ nikanṣoṣo ni a ti lee bi i, O wa nipasẹ Bẹthlẹhẹmu naa. Idi ti o fi gbọdọ jẹ ibi kekere naa niyi. Bi o ti gbọdọ ri niyi ni owurọ yi, O gbọdọ jẹ ni ọna kanna nipasẹ Ọrọ ti a ṣeleri. Bẹẹ ni, sa. Agbarijọ Filistini n ṣe agbekalẹ ara rẹ bayi, wọn n gbe ibudo ogun kalẹ nibi gbogbo yika Bẹthlẹhẹmu wa. Yika Keresimesi yi, wọn n gbe ibudo ogun yika Rẹ nigbagbogbo, wọn fi itannaa aye yi ṣe e lọṣọ. “Ah, a o mu alafia agbaye wa.” Popu Luther, John tabi ohun towu ki orukọ rẹ jẹ, yoo ṣe agbarijọ wọn, bẹẹni gbogbo awọn bisọbu nla ti ijọ, Agbarijọ Igbimọ Ijọ ati Agbarijọ Ijọ Agbaye lo n parapọ. Bawo ni eniyan meji yoo ti rin papọ bikoṣe pe wọn rẹ́? Amin!

Ẹnikanṣoṣo ni e lee rin pẹlu, eyi ni Jesu Kristi. Bawo ni ẹ ṣe lee rin pẹlu Rẹ? O jẹ nigbati ẹ ba sọkan pẹlu Ẹniti O jẹ, Ọrọ naa! Ẹ maṣe jẹki eyi fo yin ru.

94 Nko bikita nipa iye itannaa arẹwa ti ẹ gbekalẹ, “Ẹ ni lati ṣe eyi tabi ki a ti ijọ yin tabi ... Nko bikita nipa ohun ti wọn ti-pa, iyẹn ko ni ohun kan lati ṣe pẹlu Ọrọ naa. Bẹẹni, sa. Nibo ni ẹ nlọ? Eyi ni ohun ti Ọrọ sọ pe ẹ n ṣe gẹlẹ, ẹ n pada sinu rẹ, gbogbo yin wọ aṣọ itanna aye, pẹlu gbogbo ileri asan aye, ṣugbọn o jinna rere si Ọrọ ni nkan bi ibusọ miliọnu. Bi o ti ri loni niyi, Keresimesi lẹẹkansi, lati pawamọ kuro ninu ileri Ọrọ Ọlọrun. Ṣugbọn a o ṣe imuṣẹ Rẹ. Ọlọrun ni agbara lati gbe iru ọmọ dide fun Abrahamu. Ah, wọn n gbiyanju lati fi ojulowo pamọ, lati mu awọn olugbe Bẹthlẹhẹmu tootọ kuro ninu Iye Ainipẹkun, eyi ni ilepa wọn.

95 Ẹ dide, ẹyin ọmọ ati ọmọ ogun, ẹ jẹki a fi ijakadi pada si ojulowo Bẹthlẹhẹmu! Ẹ ranti Dafidi de ori itẹ rẹ. Awọn eniyan wọnyi duro ti i nitoriti wọn mọ pe ... Wọn mọ pe yoo de ori itẹ. Wọn mọ pe Dafidi yoo de ori itẹ, botiwu ki a lee jade to. Oun ni alarinkiri ti o buru ju lori ilẹ naa. Bẹẹ gẹlẹ ni ojulowo Ọrọ Ọlọrun ri, ni owurọ yi O ṣe ajeji si awọn agbekalẹ. Ẹ wo ohun ti wọn ti ṣe. Eyi fihan niwaju yin.

Awọn eniyan n gbiyanju lati sọ pe, “Arakunrin Branham, iwọ n ba awọn ijọ wi.” Agbekalẹ wọn ni mo n ba wi. Jesu Kristi ni Ijọ, ki i ṣe agbekalẹ.

96 Ati ni oni, ẹ wo ohun ti wọn ti ṣe, ẹ wo ohun ti wọn n ṣe. Ẹ si lee ri ohun ti wọn n ṣe, wọn n gbiyanju lati mu oju awọn eniyan kuro ninu iyẹn. Wọn tẹ ibudo ogun kalẹ siwaju ati siwaju ni ayika kanga naa, lati ri daju pe ẹnikẹni ko mun lati inu kanga naa. Ṣugbọn, ẹyin ọmọ ogun Ọlọrun, mo gbagbọ pe Jesu Kristi yoo de ni ọjọ kan lati inu ogo Rẹ wa, mo gbagbọ pe yoo wa, yoo si joko si ori Itẹ Baba Rẹ, Dafidi. Bi o tilẹ jẹ alarinkiri, Ọrọ Rẹ ni owurọ yi, ti awọn eniyan Rẹ kọ silẹ bi awọn eniyan Dafidi ti ṣe, awọn ẹgbẹ eniyan gbogbo kọ Ọrọ Rẹ silẹ, wọn kọ Ọ silẹ, nigbati Ọlọrun wa, ti O si ṣe ifidimulẹ ojulowo Ọrọ Rẹ. Maṣe sọ eyi fun mi! Fun ọpọlọpọ ọdun, kaakiri orilẹ ede, wọn si n jinna si i nigbagbogbo.

97 Mo sọ ni ọjọsi, nipa Jacqueline Kennedy, igba melo ni mo ti ba ẹyin obinrin wi lori bi ẹ ti n ge irun yin, ti ẹ n kun oju ati ete yin lọda, ẹyin obinrin ati ijọ awọn onigbagbọ to n fi ifedefọ ṣe ijẹri Ẹmi Mimọ ti ẹ n ge irun yin, eyiti Ọlọrun sọ pe O jẹ ... Ẹ n sọ ara yin di panṣaga oju popo nigbati ẹ bạ se bẹẹ. Bi Ọlọrun ti wi, ọkọ yin ko ni ẹtọ lati maa gbe pẹlu yin niwọn igbati ẹ ba ṣe bẹẹ. Obinrin ti o ba ge irun rẹ ṣe aibọwọ si ori rẹ, eyitiṣe ọkọ rẹ. Bẹẹ gẹlẹ ni eyi ri. Ki ni mo sọ nipa eyi? Ẹ si pe mi lori eyi, mo gba oniruru lẹta, ninu eyiti ẹ ti pe mi ni “Àgbààyà.” O dara, Wọn pe Elijah ni orukọ kannaa. Wọn pe ikọọkan Ọrọ Ọlọrun bẹẹ nigbogbo igbati a ba fi Ọrọ han, wọn pe e ni orukọ.

98 Ẹnikan sọ ni ọjọsi pe, “Eeṣe, a gba ọ gbọ bii wolii.”

Emi ko sọ eyi, nko sọ pe ... Emi ki i ṣe wolii, mo kan jẹ iranṣẹ Ọlọrun nihin, to n gbiyanju lati sọ otitọ fun yin. Koju bẹẹ lọ. Ẹ jẹki n sọ eyi fun yin, Ọrọ Ọlọrun duro fun eyi! O wipe, “Awọn ọmọbinrin Sioni, ẹka ti o ba sa asala ni ọjọ naa niti gbogbo iwa ibajẹ rẹ, yoo jẹ ologo ni oju Oluwa.” Ẹ la kaka ẹyin obinrin ẹ ni ojuṣe ti yin lati la-kaka, iṣe Ìlú ìbàjẹ ati aworan ti wọn n fihan, ati gbogbo ohun ti wọn n ṣe lori tẹlifisan, ti ẹ n gbiyanju lati ṣe awokọṣe rẹ, ti ẹ n wọ aṣọ ìwọ̀kuwọ̀ ni oju popo.

Ẹnikan si sọ pe, “Eeṣe, ohun ti awọn eniyan naa n beere fun ni ki o kọ awọn bi awọn yoo ti gba Ẹmi Mimọ ...”

Ẹ sọ pe ẹ ni Ẹmi Mimọ, ẹ si n ṣẹ Ọrọ naa, abi? Igbe-aye yin n ṣe afihan pe ẹ ko ti i gba Ẹmi Mimọ, ṣe ẹ

rii. Bayi nko binu, mo kan n sọ ohun ti i ṣe Otitọ fun yin ni. Ẹ wo ara yin ki ẹ si mọ ohun ti mo n sọ. Paulu wipe, "Ti angẹli kan lati ọrun ba kọ yin ni ohun miran, jẹki o di ẹni ifibu," Iwe Galatia 1:8. Bẹẹ ni.

99 Ti Jacqueline Kennedy ba ... O n fi awokọṣe silẹ fun awọn obinrin pẹlu gbogbo awọn irun gige ati awọn nkan wọnni to n ṣe, aṣọ iwọkuwọ wọnyi, bi aṣọ abiyamọ ati nkan bẹẹ. Gbogbo obinrin ni orilẹ ede lo fẹ wọ iru awọn aṣọ bẹẹ, eyin onigbagbọ Pẹntikọsti pẹlu fẹ ṣe bẹẹ. Ẹ wo o, Jacquline Kennedy ko gbọ iwaasu bi iru eyi ri. I bą se pe o ti gbọ iru rẹ, kì bá ti ronupiwada lati igba pipẹ wa. Ṣugbọn ẹyin obinrin ijọ onigbagbọ to n fi ifedefọ ṣe ijẹri Ẹmi Mimọ n gbọ ọ lojoojumọ, ati nigbogbo ọdun, sibẹ ẹ ko ṣe ohunkohun nipa rẹ! Hallelujah! Agara yoo da Ọlọrun nipa eyi ni ọjọ kan! Yoo ṣu Ọlọrun. Koburu, mo mọ pe ẹ n ro pe mo ti di aṣiwere. Ẹ tẹsiwaju, o dara. Wọn ro bẹẹ nigbogbo igba ijọ nigbati Ọrọ naa ... Ṣe ẹ ri i.

100 Ẹyin ọmọ ogun, ẹ fa Ida yin yọ, ẹ jẹki a duro fun ohun gbogbo ti ida naa duro fun! Ẹ jẹki a de ibi kanga naa nibiti Isun kan wa ti O kun fun Ẹjẹ, to n san ni iha Immanuẹli. Ki i ṣe iha Juu lo ti n san wa, iha Immanuẹli ni, Ọlọrun wa pẹlu wa; Ẹlẹṣẹ mòòkùn ninu ibu naa, o si bọ lọwọ ẹbi.

"Baalẹ kan yoo si ti Bẹthlẹhẹmu wa, ti yoo paṣẹ lori awọn eniyan mi." Ẹmi Mimọ si n paṣẹ lori awọn eniyan loni, Ẹmi Mimọ si ni Ọrọ naa. Ṣe bẹẹ ni? Bayi, bi a ti n wa si ipari, pẹlu ọ̀wọ̀. O n dari awọn eniyan. Ohun towu ki o ro; duro ti Ọrọ naa. Ti iwọ ko bą se bẹẹ, Ẹmi Mimọ ko si ninu rẹ; iwọ yoo ṣe ijẹri si ẹri ẹnu rẹ, ohun towu ki o sọ. O lee fo sókè-sódò, ki o fedefọ, ki o maa yi nilẹ, ki o si ge irun ori rẹ, ki o si maa ṣe awọn ohun ti iwọ n ṣe; nkan wọnyi n jẹri lodi si ọ, iwọ ko ni Ẹmi Mimọ.

101 Ẹyin olugbe Bẹthlẹhẹmu, ki Ọlọrun bukun yin, ẹ jẹki a lọ! Kristi n fẹ ojulowo Ijọ. O n fẹ Iyawo. Ẹ jẹki a lakaka. Ẹ kuro nihin, ẹ mu gbogbo ẹkọ adamọ yin lọ, ki awọn ojulowo omi lee pada wa, ki wọn o si bu Omi ojulowo Pẹntikọsti ti o tutu, eyiti O ti fi igbakan ṣàn wa lati inu kanga nla yi. O n ṣàn sibẹ. Ṣe iwọ ko ni wa loni, ki o si gba eyi gbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ, bi a ti n tẹriba fun iṣẹju kan.

Mo ni ọpọlọpọ nkan ti o yẹki n sọrọ le lori nihin. Akoko ko ni gba mi laye lati ṣe bẹẹ, agogo mọkanla ti lu nisisiyi. Nko mọ iye ọmọ ogun Ọlọrun ti a ni nihin, ẹyin iranṣẹ Ọlọrun ti ijọ Mẹtọdisti, Baptisiti, ijọ Alagba, alufa Katoliki, ohun towu ki ẹ jẹ, njẹ ẹ ni idaniloju pe otitọ ni mo sọ? Mo mọ pe emi ki i ṣe ẹni-ọwọ, ṣugbọn Ọrọ Ọlọrun niyi. Ṣe ẹ gbagbọ pe bẹẹ lori, ṣe ẹ gbagbọ pe Ọrọ Ọlọrun ni, eyi ni Bẹthlẹhẹmu naa. Jesu wipe, "Eniyan ki yoo wa nipa akara nikan; bikoṣe nipa gbogbo Ọrọ ti O ti ẹnu Ọlọrun jade wa." Ọrọ naa si wa nihin, Bibeli naa. Nipa Rẹ ni eniyan yoo wa laaye, Oun si ni Ọrọ naa.

102 Ẹyin ọmọ ogun, njẹ ẹyin yoo fa Ida Ọlọrun yọ ki ẹ si sọ pe, "Emi ko ni ifẹ si awọn igbagbọ asan wọnyi mọ, emi n padabọ si inu Ọrọ naa, emi n padabọ sinu Otitọ?" Ẹyin obinrin, ati ọkunrin! Ẹyin obinrin, ṣe oju ara yin ko ti yin, pẹlu ọna ti ẹ n gba wuwa? Njẹ ẹyin nfẹ ni owurọ yi, ni akoko Keresimesi yi, lati pada wa, ki ẹ si se afihan Jesu Kristi tootọ?

Bayi, pẹlu ori ti ẹ tẹba ati gbogbo oju ti ẹ pade, njẹ ẹyin yoo na ọwọ yin soke, ki ẹ si sọ pe, "Gbadura fun wa, Arakunrin Branham. Lootọ emi fẹ ṣe eyi ninu ọkan mi ... Mo gba a gbọ?" Ki Ọlọrun bukun yin. Akiika, ẹyin iranṣẹ Ọlọrun, ẹyin obinrin, nibi-gbogbo!

103 Ni Bẹthlẹhẹmu ... Bẹthlẹhẹmu, ile Ounjẹ ati Omi Ọlọrun, Kristi, Bẹthlẹhẹmu ologo wa. Bawo ni awa ṣe lee wọ inu Rẹ? Iwe Kọrinti kinni ori kẹẹdogun, "Nipa Ẹmi kan ni a batisi gbogbo wa sinu ara Jesu Kristi."

A n jẹ ninu Ọrọ Rẹ, ki i ṣe ohun miran, Ounjẹ aguntan nikan ni! Ọrọ naa! Ko si ohun miran. Iwọ ko lee fi ẹkọ adamọ kan sinu Rẹ, awa ko ni feti si i. Rara, ṣa. Ti o ba sọ pe, "Ọna yi ni." Ti bibeli ba sọ pe ọna yi ni, ọna ti a wa n gba fẹ ẹ niyi. A ko fẹ ki a fi adun atọwọda si i. A fẹ ẹ ni ọna ti Iwe Mimọ gba sọ ọ.

104 Ọlọrun Baba wa, loni, awọn ọkan ti ebi n pa wa ti o ṣẹku si ori ilẹ aye. Eeṣe ti o jẹ Bẹthlẹhẹmu kekere? Ni ọna òpè ti emi, Oluwa, mo ti gbiyanju lati mu ki ẹgbẹ kekere yi ... Eyi ti o fẹran mi, mo mọ pe wọn fẹran mi, Oluwa. Emi pẹlu si fẹran wọn. Mo si fẹran wọn, Oluwa, to bẹẹ gẹẹ ti, mo ni itara fun wọn. Nko fẹ lati ri ki wọn o darapọ mọ awọn nkan nla wọnyi, ki a si ke wọn kuro nigbati akoko ba ti pẹju, ti ọkan otọṣi wọn si ti wa ninu igbekun, ki wọn o to mọ pe awọn ti ni anfani nigbakan ri lati sa asala.

Oluwa Ọlọrun wa, loni, ohun towu ki Jerusalẹmu nla-ni ro, ati ohun towu ki Gileadi ati Ramot-gileadi ati ilu miran ti o lee jẹ ro, Awọn ilu Shilo ati awọn ibi ijọsin nla wọnni, ibikibi towu ki wọn o wa. Bẹthlẹhẹmu kan mbẹ. "Iwọ ko ha jẹ ilu to kere ju laarin awọn yooku? Ṣugbọn ninu rẹ ..." Lati inu Mẹtọdisti, Baptisti, ijọ Alagba; Ijọ Katoliki, awọn olu ijọ nla; ati Ramot-gileadi, nibiti Luther ti ja; ati ni awọn Shiloh, nibiti o ṣeeṣe ki Wẹsili ti ja; ati ọpọlọpọ ibi. Ṣugbọn, Oluwa, Oluwa, Iwọ gbe ẹgbẹ onigbagbọ to n fi ifedefọ ṣe ijẹri Ẹmi Mimọ dide, nko si mọ́ bi awọn pẹlu ko ba ti i yipada, ki wọn o si ti ṣe ohun kannaa.

105 Jesu Nasarẹti, mo bẹ̀ Ọ, Oluwa, lati jẹki awọn ọmọ ogun dide ni orukọ Rẹ lati inu awọn ẹkọ adamọ wọn, ki wọn o fi ida wọn la ọna lati inu awọn ẹkọ adamọ naa, ki wọn o si pada sinu otitọ Ọrọ ti ko labula, ki wọn o pa gbogbo idiwọ ti o rọrun lati di mọ wọn ti si apa kan. Ki wọn o pa gbogbo wakati ti wọn ti fi wa nihin ti wọn n

fi iwa aigbọn lọ kaakiri lati wa ọmọ ẹgbẹ fun agbekalẹ kan ti. Oluwa Ọlọrun, jẹki wọn o pada wa lati jere ọkan si Jesu Kristi, ki i ṣe lati fi ogo fun agbekalẹ kan, tabi ẹnikẹni, bikoṣe Jesu Kristi, ani Oun nikan.

Dafidi ni awọn ọmọ ogun naa ja fun, Dafidi ni wọn fị emi wọn wéwu fun. Awọn ọmọ ogun ati jagunjagun nla naa, laisi ibẹru, wọn lọ sibẹ, nitoripe iyẹn jẹ ifẹ ọkan rẹ. Ifẹ ọkan rẹ̀ ni lati mun omi ti o ti inu kanga naa wa.

Oluwa Ọlọrun, boya a ko ni imọlara, lati ja bẹẹ, ṣugbọn, Iwọ, ifẹ ọkan Rẹ nipe ki a ṣe awọn nkan wọnyi, Bi O ti sọ fun Johanu, Pe, "Bẹẹ ni o tọ fun wa lati mu gbogbo ododo ṣẹ, ohun ti o tọ fun wa, ni ki a mu gbogbo ododo ṣẹ."

O tọ fun wa, gẹgẹ bi iranṣẹ Ọlọrun loni, lati ri pe a waasu Ọrọ yi, lati ri pe a ṣe e. Bẹẹ ni o tọ fun wa, awa eniyan akoko ti a n gbe ninu rẹ yi. Awọn eniyan nla ti o wa lori ilẹ aye loni, Ọlọrun, wọn wa lọhun, jẹki wọn o ri i, ki wọn o si gba Ida naa mu! Iru atako towu ki ẹ ni, ti Ọlọrun ba wa fun yin, talo lee doju ija kọ yin? A ko bikita lati fi igbe aye gbajumọ wa wewu, a ko bikita lati fi eyi, iyẹn, tabi omiiran wéwu, a fẹ ni Omi Iye pada!

106 Ẹ jẹki a lọ si Bẹthlẹhẹmu, Oluwa, jẹki ẹnikọọkan wọn. Jẹki gbogbo awọn obinrin wọnyi, dajudaju, ti wọn ba na ọwọ wọn soke, a jẹ pe oju ara wọn ti ti-wọn ni. Jẹki wọn o mọ pe awọn ọkunrin wọnyi yoo da bi Ogbẹni Kennedy ni ọjọ kan. Wọn yoo da bi awọn ọkunrin yooku, wọn ni lati ku. Awọn obinrin wọnyi n ku lọ. Emi n ku lọ. Gbogbo wa la n yọ́ lọ ni ori ilẹ aye nihin, ki wọn o si mọ pe akoko diẹ ni a ni, diẹ ni ọjọ eniyan ku lori ilẹ aye. Atipe, Ọlọrun, dipo ki a maa kọ agbekalẹ nla, Oluwa, jẹki awọn ọkunrin ati awọn obinrin ri eyi ni owurọ yi pe bíbọ̀ Ọba ni.

Ọlọrun, bibọ Ọba nla ni, Jesu! A si loye eyi, Ọlọrun, pe ikọọkan awọn ọmọ ogun naa ti wọn fa ida wọn yọ ti wọn si jà fun Dafidi nigbati o jẹ alarinkiri, nigbati o de ipo agbara, o fi wọn ṣe baalẹ lori awọn ilu. Ikọọkan wọn ni ilu to sakoso. Bẹẹni Iwọ ṣe ileri eyi ninu Bibeli, pe awa yoo ni awọn ilu. Ọlọrun, bi keferi, O sọ keferi di ajogun, ki awa lee ni ipin ninu Iwa Mimọ ati ododo Rẹ! Jẹki awa loni, Oluwa, bi ọmọ ogun naa gba Ọrọ naa, bi a ti mọ pe, awọn ti wọn duro fun Un ni wakati yi, wọn yoo di baalẹ lori awọn ilu. Ki i ṣe bi awa ti fẹ di apaṣẹ, ṣugbọn a fẹ di iranṣẹ si Ọ Oluwa. Ọlọrun, a ri iran ẹgbẹ kekere yi, ijọ kekere yi, eyi ni ohun ti wọn pe ni akatakiti ... Paulu sọ ni ọjọ rẹ pe, "Ni ọna ti wọn n pe ni iṣiwere." Ibẹ ni emi ti fẹ ja, Oluwa. Otitọ ni Ọrọ Rẹ! Iwọ ni Ọrọ naa, ọkan naa lana, ati loni, ati titi laelae.

107 Ọlọrun, ta ororo Ọrọ Rẹ le wa lori, ki O si mu Ọrọ Rẹ ti O ṣeleri fun ọjọ oni wa si imuṣẹ. Jẹki a fi gbọngan yi silẹ ni owurọ yi bi ohun elo Ọlọrun to n tan. Jẹki a lọ pẹlu Ida naa, O n kọ-mọ̀nà ninu afẹfẹ, lati ge gbogbo idiwọ ati ohun gbogbo miran, titi ti a o fi lee mu awọn eniyan naa pada si ọdọ Kristi, ki a si mu omi tutu daradara wa fun Oluwa wa, dipo awọn omi adagun ẹkọ adamọ wọnyi. Jẹki awọn eniyan naa mu lati inu Isun naa, ti i ṣe ti itura ibukun Pẹntikọsti, ki o lee bukun Ọkan Rẹ, ki o si mu Un pada wa si ọkan wa lẹẹkansi i. Ṣe e, Oluwa. Ni orukọ Jesu, ni mo gbadura.

108 Nigbati a si n tẹriba, ti atẹduru, tabi ohun ti o ba jẹ, ti yoo ba lọ si ibi duru naa, mo fẹ ki a kọ orin yi jẹjẹ, "Isun kan mbẹ ti o kun fun ẹjẹ, to n sàn ni iha Immanuẹli; ẹlẹṣẹ mòkùn sinu ibu naa ..." Ẹlẹṣẹ, ta ni ẹlẹṣẹ? Alaigbagbọ. "Alaigbagbọ mòkùn ..." Aigbagbọ ninu ki ni? Orọ naa. Ah, awọn Juu naa, wọn ko fẹ gbagbọ pe alaigbagbọ ni awọn, wọn ro pe a ti gba awọn la, ṣugbọn Ọlọrun mọ pe wọn nilo Olugbala kan. Wọn n gbadura fun balogun kan, Ọlọrun fun wọn ni ọmọ ọwọ, Olugbala kan. Ọlọrun mọ ohun ti wọn nilo. Eyi ni ẹbun Keresimesi wọn. Eyi ni ohun ti o nilo loni, eyi ni ohun ti mo nilo loni, Olugbala kan fun aigbagbọ mi, Olugbala kan fun aigbagbọ rẹ. Nigbati a n kọ orin yi, ẹ jẹki a gbadura nipa rẹ ninu ọkan wa bayi. Ẹ gbadura nitootọ, ẹ jọwọ, ijọ.

Isun kan mbẹ to kun f'ẹjẹ,

To n sàn ni'ha Immanuẹli,

Ẹlẹṣẹ (awọn alaigbagbọ) mòkùn

(Ki i ṣe ọmọ ijọ) ...

(Inu rẹ ni awọn ọmọ ijọ ti mòkùn.)

Wọn bọ lọwọ ẹbi.

Wọn bọ lọwọ ẹbi;

Wọn bọ lọwọ ẹbi;

Ẹlẹṣẹ ...

109 Jesu Oluwa, mo gbadura nisisiyi pe Iwọ yoo gba wa. Mo n fi ara mi sihin pẹlu awọn ẹgbẹ eniyan yi,

Oluwa. Mu gbogbo aigbagbọ mi, Oluwa, kuro lọdọ mi. Jẹki n ku, Oluwa, bi Samsoni ti ke, jẹki n ku pẹlu awọn Filisitini yi. Jẹki n ṣe ohun gbogbo ti mo ni lati ṣe, ṣugbọn Ọlọrun, fọ ọkan mi mọ. Mu gbogbo iyemeji lọ. Ti ohun kan ba wa ninu Ọrọ yi ti nko gbagbọ, Oluwa, ti ko ba si ohun kan nihin ti Iwọ ti ṣeleri, ti nko lee ri aye mi ... ṣe ifidimulẹ Ọrọ naa ti O ṣeleri fun ọjọ oni, nigbana, Oluwa, dariji mi. dariji mi, Oluwa.

Fun mi ni imọkanle. Oluwa, mo nilo imọkanle lati ké nkan yi lulẹ, lati ké odi yi, nitoriti emi mọ pe ifẹ Rẹ ni. Iwọ ti sọ Ọ, O gbọdọ ri bẹẹ ni ọjọ oni, "Bi o ti ri ni ọjọ Sodomu, bẹẹ ni yoo ri ni igba wiwa Ọmọ eniyan." A ri isọji ikẹyin yi, iṣẹ-ami ikẹyin yi ti a ti fifun ijọ. Iyẹn ni ami to gbẹyin ti a fihan si iru ọmọ Abrahamu nipa ti ara, ki ina to jo aye keferi. Iwọ ... Oluwa, jẹki wọn o ri i pe idi ti a fi gbọdọ bi Jesu si Bẹthlẹhẹmu gẹlẹ niyi. Ọrọ Rẹ ni. Ileri Rẹ ni. Bukun wọn nisisiyi, Baba. Mo fi wọn fun Ọ, bi èrè ìpè naa. Jẹki awa, lapapọ, Oluwa, fa Ọrọ naa yọ loni, ki a si tẹsiwaju ni orukọ Jesu. Amin.

110 Ki Ọlọrun bukun yin. Njẹ ẹ fẹran Jesu Oluwa? Njẹ ẹ gbagbọ pe Otitọ ni Ọrọ naa? E na ọwọ yin soke ti ẹ ba gbagbọ pe Otitọ ni. Ẹ ṣeun, ẹyin ọrẹ. Ẹ woo, emi ... Mo ro pe wọn ti pa ẹrọ to n ka ohùn naa silẹ. Ṣe ẹ rii, ni sisọrọ nihin, nko maa ba yin sọrọ lasan. Ohùn naa n lọ si ibi gbogbo ni agbaye, awọn eniyan ni agbaye yoo si gbọ ọ. A ti lọ si oniruru orilẹ ede ... Wọn n joko pẹlu ohun kan ni eti wọ, mo si n sọrọ si ọgọọrun eniyan ni agbaye.

111 Ki ẹ si wo o, ki i ṣe ... Ki i ṣe ẹyin obinrin ni mo n ba wi, nko fẹ lati pa yin lara nigbati mo ba n sọ awọn nkan wọnni fun yin. Ṣugbọn ti Pasitọ yin ko ba sọ eyi fun yin, ohun kan kuna pẹlu rẹ. Ko ni igboya lati ṣe bẹẹ. O n farasin si abẹ ẹgbẹ eniyan. Tabi ki o da bi Lọti, to n joko sibẹ, ki ina to sọkalẹ lati ọrun, oun ko ni ohun ti o nilo lati duro fun Ọlọrun nibẹ ... Bibeli sọ bẹẹ, "Ẹṣẹ Sodomu mu ọkan ododo rẹ saarẹ." Ọkàn rẹ mọ dara ju bẹẹ lọ, ṣugbọn oun ko ni ohun ti o nilo lati duro sibẹ ki o si da ẹṣẹ lẹbi. Bẹẹni Pasitọ ti ko ni sọ fun obinrin kan pe o lodi fun un lati ge irun ori rẹ, ohun kan kuna pẹlu iru ọkunrin bẹẹ, ati lati ri pe wọn n wọ iru awọn aṣọ ẹ̀ṣẹ̀ wọnyi lai sọ ọrọ lodi si i.

112 Ẹyin ọkunrin pẹlu, ẹyin ọkunrin ti ẹ o gba awọn iyawo yin laye lati ṣe iru nkan bẹẹ, ki lo n ṣe yin? Ki lo n ṣe yin? Ẹ nlọ pẹlu iyawo yin ni igboro, pẹlu imura panṣaga, ti ẹ o si gbá eyikeyi ọkunrin ti o ba kan an labuku leti. Ẹ yin gan an ni ẹ nilo ìgbánu. Bẹẹ ni, Ọlọrun yoo si ṣe bẹẹ fun yin lọjọ kan, pẹlu. Bẹẹ ni. A ni lati pada sinu Ọrọ yi.

Ki i ṣe eyi nikan, kekere ni eyi. Ṣugbọn bawo ni ẹ o ti ṣe loye ohun nla ti ẹ ba kọ kekere wọnni silẹ? Ẹ o ti ṣe ni opin imọ nigbati ẹ ba kọ ipiliẹṣẹ ẹkọ silẹ? Ti ẹ ko ba lee ka oókan si ẹẹwa, bawo ni ẹ o ṣe ni imọ ìṣirò? Ẹ ni lati bẹrẹ lati ibẹrẹ. Ẹ n gbiyanju lati de oke tente. Ẹ pada silẹ, ki ẹ si bẹrẹ daradara.

Akoko naa niyi lati ṣe e, akoko Keresimesi. Ibi Kristi ni, ẹ jẹki a bi Kristi sinu wa. Tani Kristi? Kristi ni Ọrọ naa. Eniyan melo ni o mọ eyi? "Ni atete kọṣe ni Ọrọ wa, Ọrọ si wa pẹlu Ọlọrun, Ọlọrun si ni Ọrọ naa."

113 Ẹnikan sọ ni ọjọsi, pe, "Arakunrin Branham ... Awọn eniyan mọ pe akorira obinrin ni iwọ i ṣe." Emi ki i ṣe bẹẹ. Emi ki i ṣe bẹẹ. Mo ni ifẹ tootọ fun awọn obinrin mi. Ọkunrin ti yoo wo yika, yoo si ro pe iwọ rẹwa pẹlu oju ti o kun lọda oriṣiriṣi ati irun ti o ge, iru ọkunrin bẹẹ ni ero ọtọ si eyi ti emi ni. Mo fẹran ọkàn ti o wa ninu yin, oun ni yoo ba Ọlọrun pade. Eyi ni idi ti ... Arabinrin mi, nitori ainipẹkun ni, ki i ṣe nitori ọrọ akọ si abo lori ilẹ aye nihin ...

114 Eniyan melo lo ti ka nipa iṣubu ilẹ Romu? Dajudaju. Ẹ wo ibẹyẹn, ohun kannaa ti awa n ṣe loni niyi, imura irira. Awọn ọdọ ti o wa ninu ipo ti wọn wa loni, bi a ti ri nisisiyi iṣoro ìran ati ẹya. Ati igbekun awọn ọ̀dọ́, awọn ọkunrin pẹlu ọ̀rọ̀ ibalopọ. Bi Ijọba Ilẹ Romu ti ṣe ṣubu niyi, ni ẹgbaa ọdun kan din ni igba sẹyin, iṣe naa si ti pada si aarin Keferi, ṣe ẹ rii. Irukerudo laarin awọn ẹsin ati nkan bẹẹ. Ah, iru wakati wo la wa ninu rẹ yi.

[Arabinrin kan jẹ iṣẹ Kan.] Amin. Oluwa Ọlọrun ti sọrọ. Mo gba eyi gbọ.

115 Ẹ jẹki a duro nisisiyi. Nigbati Oluwa ti sọrọ, akoko ni eyi fun wa lati bọwọ fun. [Ẹnikan ba Arakunrin Branham sọrọ] Nipa oore-ọfẹ Ọlọrun, ati iranlọwọ Ọlọrun, mo ti ṣe ipinnu ju ti atẹyin wa lọ, lati duro ti Ọrọ yi, ki n sį sa gbogbo ipa mi, nipa iranlọwọ Ọlọrun, lati la-kaka pẹlu ijakadi lọ si Bẹthlẹhẹmu lẹẹkansii, nibiti awọn olugbe Bẹthlẹhẹmu ti lee mun omi lati inu Isun naa wa. Eniyan melo ni yoo darapọ mọ mi, pẹlu ọwọ yin loke, ẹ sọ pe, "Emi ṣe ileri si Ọlọrun pe emi yoo ṣe bẹẹ? Ki Ọlọrun bukun yin.

Bayi, ẹ tẹriba fun iṣẹju kan, mo si gbagbọ pe arakunrin kan nihin, Arakunrin Jefferies, wa sihin. Oun ni yoo fun wa ni adura ipari nigbati a n tẹriba ninu adura, ti iwọ yoo bą se bẹẹ. O dara, arakunrin.

www.messagehub.info

Ìwàásù lati ẹnu

William Marrion Branham

"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7